# OBÌNRIN BÍ OLÙKỌ́ ÌDÍLÉ

Mary Owólabí

**OBÌNRIN BÍ OLÙKỌ́ ÌDÍLÉ**
Láti ọwọ́ Díákónì Obìnrin Mary Owólabí
Copyright © 2017

**Àṣẹ tí a Kò fún ni.**

Pé a kò fún ẹnikẹ́ni láṣẹ láti tún kọ tàbí dàkọ apá kan nínú ìwé yìí ní ọ̀nàkọnà yálà nípa ẹ̀rọ ayárabíàṣá tàbí àwọn ọ̀nà mìíràn láì gba àṣẹ láti ọwọ́ òǹkọ̀wé; àyàfi lílò fún bíi àkàjúwe tí ó ṣe kókó.

Gbogbo àkàjúwe ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí a lò jẹ́ ti ìwé mímọ́ King James Version àti New Living ti Bíbélì Mímọ́.

Fún àdúrà àti ọ̀rọ̀ ìyànjú, jọ̀wọ́ pe òǹkọ̀wé:
**The Divine Message and Great Mission**

Sórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ yìí:
+2348140606077; 07055512708

Ẹ̀rọ ayárabíàṣá:
thedivinemessageandgreatmissio@gmail.com

**ISBN:** 978-978-52841-8-8



# TÁBÌLÌ ÀKỌ̀RÍ

Ìpè Iránṣẹ́ ... ... ... ... ... iv
Ọ̀rọ̀ Àkọ́sọ ... ... ... ... ... v
Ìfijì ... ... ... ... ... ... vii
Ìmọríri ... ... ... ... ... viii
Ìfáàrà ... ... ... ... ... xi
Ìtumọ̀ Èdè ... ... ... ... ... xii

**ORÍ KÌN-ÍN-NÍ**
Obìnrin bí Olùkọ́ Ìdílé ... ... 1 - 28

**ORÍ KEJÌ**
Oníwàrere Adé Orí fún Ọkọ ... 29 - 40

**ORÍ KẸTA**
Àwòkọ́ṣe ... ... ... ... 41 - 53

**ORÍ KẸRIN**
**Àkótán** ... ... ... ... 54 - 58

# ÌPÈ ÌRÁNṢẸ́

"Ẹni tí Ọlọ́run pè tí ó sì rán láti dín èrò ìjọba èṣù kù ní kíkọsílẹ̀ nípa ìtọ́ni àti ìfihàn àtọ̀runwá àti títọ́sọ́nà nípa agbára Ẹ̀mí Mímọ́, láti tú àṣírí tí ó n darí ẹni sí dídi ọ̀mìnira, láti sìpẹ̀ fún àti láti gba àwọn ọmọ Ọlọ́run níyànjú ní gbogbo ayé, kí á ba le jèrè wọn padà sínú ìjọba Ọlọ́run tó ga jùlọ."



# Ọ̀RỌ̀ ÀKỌ́SỌ

Láti inú àwọn ohun tí a kọ sílẹ̀ nínú ìwé tí o mú lọ́wọ́ yìí, a ó kọ́kọ́ ṣe àkíyèsí pé, ìgbéyàwó, bí a ti fihàn, fi ara mọ́ ìwà títọ́ àti ìwà mímọ́. Èyí ṣe é rí látàrí pé ó n kọ́ àwọn tí ó kàn láti gbé ìgbé ayé rere àti láti ní ìpìlẹ̀ wọn nínú Kristi, nítori ìgbéyàwo ní iṣẹ́ pàtàkì láti ṣe nínú àtúntò àwùjọ.

Díákónì obìnrin Owólabí kò fi nkànkan sílẹ̀ láì yẹ̀ wò nípa títọ́ka sí bí ó ti nílò láti gbé ètò ìyípadà ara ẹni wọ inú ìrínàjò ẹ̀mí rẹ àti bí Ọlọ́run ṣe n bá ọ sọ̀rọ̀ nípa àwọn ohun tí o ní láti yí padà fún àti kọ́ ìdílé lọ́nà tó tọ́. Ó sì tún fi hà wí pé ọ̀kan gbòógì ínú àwọn orísùn ìbáṣepọ̀ ti ẹ̀mí fún lọ́kọláyà ní àkópọ̀ ìmọ̀ àti òye wọn nípasẹ̀ ìbánijírọ̀rò.

Ìwé yìí sì ti fihàn ọ̀nà tí àwọn obìnrin tí ó n kọ́ ìdílé wọn ò fi ní máa fi ìmọ̀ ìṣọ̀kan

ẹ̀mí wọn wé ohunkóhun bíkòṣe sísúnmọ́ Ọlọ́run wọn, fún ohun tí wọ́n fẹ̀ fún ara wọn.

Nítorí náà, mo kí ọ káàbọ̀ sí ibi ìsun ọgbọ́ n àti ìrètí ní kíkọ́ ìdílé, ó jẹ́ iṣẹ́ tí ó n fi orí ẹni pamọ́ tí ó sì n dáàbò bo ìgbéyàwó ẹni.

Olùsọ́-àgùntàn (Ọ̀mọ̀wé) G. O. Olútọ́lá (JP)
Ààrẹ TAC Nigeria/Alága Àyíká LAWNA
2009 - 2017



# ÌFIJÌ

Ìwé yìí ni mo fi jì fún Ọlọ́run nípasẹ̀ Olúwa wa Jésù Krístì. Aṣẹ̀dá ọ̀run òn ayé. Ẹni tí ó dá mi ní obìnrin. Bàbá, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ rẹ tí o dá mi ní obìnrin.

# ÌMỌRÍRÌ

Mo fi ògo àti ọlá fún Ọlọ́run tó ga jùlọ nípasẹ̀ Olúwa wa Jésù Kristì fún ore-ọ̀fẹ́ àtọ̀runwá tí ó fi fún mi láti ṣa àkọsílẹ̀ yìí jọ. Mo dúpẹ́ fún ìtòni ìgbà gbogbo, dídá àti mímọ mí ní ọ̀nà tí ó wù ọ́, fún ògo rẹ nìkan. O ṣeun Jésù.

"Ọkọ mi", àìláfiwé ni yín. Mo dúpẹ́ lọ́ wọ́ yín gidigidi, mo sì dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run fún ore-ọ̀fẹ́ rẹ̀ lórí ayé yín. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run pé ó fi yín fún mi gẹ́gẹ́bí ọkọ lòdì sí ìfẹ́ àti ìpinnu ọ̀tá. Mo nífẹ̀ ẹ́ yín púpọ̀púpọ̀, ọkọ mi ọ̀wọ́n.

Sí àwọn ọmọ mi, Ọlọ́run ló fi yín fún mi, ìní rẹ̀ sì ni yín. Èrò àtọ̀runwá Rẹ̀ fún un yín yíò wá sí ìmúṣẹ dandan ní orúkọ Jésù, Àmín. Mo nífẹ̀ ẹ́ yín, mo sì dúpẹ́ lọ́ wọ́ yín.



Sí bàbá mi tí ó ṣe iyebíye nínú Olúwa, Olùṣọ́àgùntàn (Ọ̀mọ̀wé) G.O. Olútọ́lá (JP), (Ààrẹ Ìjọ Aposteli Náà ní orílẹ̀èdè Nigeria àti alága àyíká LAWNA àná), ẹ̀bùn ni ẹ̀ jẹ́ fún ìran yìí. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run nítòótọ́ fún oore-ọ̀fẹ́ Rẹ̀ lórí ayé yín. Pààpàá bí ó ti fún yín ní oore-ọ̀fẹ́ àtọ̀runwá àti ìṣípayá láti ṣiṣẹ́ nínú èròngbà, ìfẹ́ àti ètò àtọ̀runwá rẹ̀ fún Ìjọ Aposteli Náà, pàtàkì jùlọ́ ní àkókò òpin ayé yìí. Olúwa nínú ètò àtọ̀runwá Rẹ̀ tí ó ti pinnu láti lo àwọn obìnrin ní àkókò òpin ayé yìí, náà ni ó ti yàn yín láti darí wọn sí ibi pípé ìfẹ́ Ọlọ́run fún ayé wọn sí ògo Rẹ̀ nìkan. Ọjọ́ tí ẹ sọ fún mi pé kí n mú ẹ̀rù kúrò tí ẹ sì mú mi lòrí yá láti tẹ̀síwájú nínú iṣẹ́ ìránṣẹ, ọjọ́ náà ni mo mọ̀ wípé Olúwa ti ṣetán láti bẹ ìjọ rẹ̀ wò lẹ́ẹ̀kan is. Bàbá, mo yìn Ọlọ́run fún ayé yín.

Olùsọ́àgùntàn àti Díákónì obìnrin T. Agbẹ́ja, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run fún ayé

yín, pàápàá fún àdúrà àti àwọn ọ̀rọ̀ ìmóríyá yín. Màmá, àwọn ọ̀rọ̀ ìmóríyá yín kò ṣè gbàgbé. Àdúrà mi ni wí pé, títí laí ni ẹ ó máa ri bí àwọn ọmọ yín tí n ṣiṣẹ́ fún Ọlọ́run Ẹlẹ́dàá wọn.

Díákònì obìnrin G.O. Fàlàsínú, obìnrin tó lóye ni ẹ jẹ́. Ọlọ́run mọ̀ yín, Ó sì ti fi yín fún iṣẹ́ ìránṣẹ́ náà, Ó sì tún fun yín ní ore-ọ̀fẹ́ láti gba ìpè Rẹ̀ lórí yín. Mo nífẹ̀ yín mà, mo sì gbàdúrà wípé, a ò ní pàdánù adé ológo pẹ̀lú ìràwọ̀ dídán tí Ọlọ́run ti pèsè sílẹ̀ dè wá ní ìjọba Rẹ̀. Àmín.



# ÌFÁÀRÀ

Láti kà ọ́ kún àwọn obìnrin oníwà bí Ọlọ́run, ní àkókò òpin ayé yìí, àti pẹ̀lú kí o ba lè ní ìdílé aláyọ̀ tí o ṣàfẹ́rí, o gbọ́dọ̀ kọ́ ìdílé rẹ àti ayé rẹ lórí Jésú Krístì àpáta. O gbọ́dọ̀ mọ amọ̀ lórí ìpìlẹ̀ yìí bí onímọ̀ẹ̀rọ nì bá ṣe fún ọ ní ìtọ́ni. Ìbẹ̀rù Ọlọ́run gbọ́dọ̀ wà nínú rẹ̀, kí o ba lè ní ìmọ̀ láti jọba lórí ayé rẹ. Gbígba agbára Ẹ̀mí Mímọ́ láàyè láti darí rẹ ni yíò fún ọ ní ọgbọ́n tí o nílò láti ní ìní àti láti gbé nínú áyọ̀ tí Ọlọ́run ti fi fún ọ. Àwa obìnrin ni adé ògo àwọn ọkọ wa, nítorí náà, làkàkà láti wà ní ipò tí Ẹlẹ́dàá rẹ fi ọ́ sí. Ṣíṣe ìtọ́jú tó péye fún àwọn ọkọ wa àti mímọ inú Ọlọ́run fún àwọn ọmọ wa jẹ́ ìpele pàtàkì nínú ìgbéyàwó wa. Mo gbàdúrà pé Olúwa Ọlọ́run yí ò ràn wá lọ́wọ́ láti jẹ́ obìnrin pípé, a ó sì báa jọba ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.

# ÌTUMỌ ÀWỌN ÈDÈ

**Ìdílé:** Ìdílé níbi yìí ni a le túmọ̀ sí ẹbí, tí wọ́n n gbé pọ̀ àti bí wọ́n ṣe n hùwà.

**Kíkọ́/Mímọ:** Láti ṣẹ̀dá ohun kan, láti gbékalẹ̀, láti kó jọ, láti gbé dide tàbí láti mú ohun kan dàgbà, láti dá sílẹ̀, láti sà jọ. Èyí ni pé láti mú àwọn oríṣi ẹ̀yà ohun kan papọ̀ di ọ̀kan.

**Olùkọ́lé/Amọlé/Ọ̀mọ̀lé:** Ènìyàn tí ó jẹ́ pé iṣẹ́ rẹ̀ ni láti kọ́/mọ tàbí tún ilé ṣe. Ènìyàn tàbí ohun kan tí ó n kọ́, dá sílẹ̀, tàbí mú

## ORÍ KÌN-ÍN-NÍ

# OBÌNRIN BÍ OLÙKỌ́ ÌDÍLÉ

## ÀLÀYÉ LÓRÍ ÀWỌN ÀKÒRÍ

**ILÉ:** Ilé tí à n sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ níhìnín yìí túmọ̀ sí ìdílé tí wọ́n n gbé papọ̀ àti bí wọ́n ṣe n hùwà.

**KÍKỌ́:** Síṣẹ̀dá ohun kan, láti kọ́ nípa títò papọ̀, láti gbé dúró, láti dá tàbí sisẹ ìdàgbàsókè lórí ohun kan, láti tò papọ̀, tó túmọ̀ sí ká to gbogbo ẹ̀yà ohun kan papọ̀.

**Ọ̀MỌ̀LÉ:** Eni ti ó yan isẹ́ ilé kikó tàbí kí á tún ilé ṣe láàyò. Ènìyàn tàbí ohun kàn tí ó n kọ́, sẹ̀dá tàbí siṣé lórí ohun kan láti gbèrú si.

## ÌFÁÀRÀ

Nígbà tí a bá sọ pé **"obìnrin bí olùmọ ìdílé"**, à n ṣe àpèjúwe obìnrin, ipò wa ní ayé àwọn ọkọ àti ọmọ wa. Ó ṣe pàtàkì láti



dojúkọ otítọ bí ìgbé ayé ṣe rí gẹ́gẹ́ bí obìnrin. Àwon ojúṣe wa kaniláyà, ṣùgbọ́ n pẹ̀lú Ọlọ́run, Bíbélì sọ pé, ohun gbogbo ni ṣíṣe.

A n kó ipa nlá nínú ayé àwọn ẹ̀bí wa. Nínú ìdílé, bí obìnrin tàbí ìyá bá kùnà nínú ojúṣe rẹ̀, ewu àti ikùnà ọkọ àti àwọn ọmọ rẹ̀ bákannáà ga púpọ̀. Àfi nípa ore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run ni ọkọ àti àwọn ọmọ bẹ́ẹ̀ fi le dúró. A ní láti mọ̀ wípé, irú ìdílé tí à n kọ́ ní ṣe pẹ̀lú ọjọ ọ̀la àwọn ọmọ wa. Mò n sọ èyí kí á le mọ pàtàkì ojúṣe wa gẹ́gẹ́bí obìnrin nínú ìdílé. Mo gbà á ládùúrà pé kí Ọlọ́run alágbára kí ó ràn wá lọ́wọ́ ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.

Ohun tí ó mú ìwé yìí yàtọ̀ ẹ̀wẹ̀, ni ọ̀nà tí Ọlọ́run ti pinnu láti mú wa lọ pẹ̀lú rẹ̀ nínú ìrìn àjò àti ṣe iṣẹ́ agbára. Ó ti ni lọ́ kàn láti fi hàn fún wa, ọ̀nà tí ó dára jù láti ṣe bí ìyá nínú ìdílé. Ó n fẹ́ kí á jẹ́ olùkọ́lé tó dára fún ìdílé wa. Mo gbàdúrà pé Òun

fúnra Rẹ̀ yíò ràn wá lọ́wọ́ ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.

Bíbélì sọ nínú Orin Dáfídì 127:1 - **"Bíkòṣepé Olúwá bá kọ́ ilé náà, àwọn tí n kọ́ọ n ṣíṣẹ́ lásán: bíkòṣepé Olúwa bá pa ìlú mọ́, olùṣọ́ jí lásan."**

A kò lè jẹ́ olùkọ́ ìdílé bí Krístì ò bá tíì kọ́ tẹ́mpìlì rẹ̀ sínú ayé wa. Bíbélí tún sọ nínú 1Kor 3:6-7 **"Èmí gbìn, Apollò bomirin; ṣùgbọ́n Ọlọ́run ní n mú ìbísí wá. Njẹ́ kì í ṣe ti òngbín nkankan, bẹ́ẹ̀ni kì í ṣe ẹni tí ó n bomirin; bíkòṣe Ọlọ́run tí ó n mú ìbísí wá."**

Nítorí náà, ó yẹ kí á mọ̀ wípé bí ó ti wù kí ìfọkànsí tàbí ìjẹlógún wa nípa ti ara àti ìnáwó sí kíkò ìdílé wa kí ó rí, ìgbé ayé àdúrà wa jẹ́ ohun pàtàkì. Ó jẹ́ ọ̀kan gbógì nínú àwọn ẹ̀yà ara fún kíkọ́ ìdílé wa.

Apá kìn-ín-ní orí yìí gbé púpọ̀ sórí nínú wípé kí o kọ́ ìdílé rẹ dáradára. Àwọn



ojúṣe yókù tí wọ́n jẹ́ òdú ti wọn kìí ṣàìmọ fún olòko wa kóó ìpín kan nínú ìdá mẹ́rin. Fiyèsi wí pé méjèèjì gbọ́dọ̀ gbé ìwọ̀n kannáà lórí òṣùwọ̀n ìdin kí á baà lè ní ìdílé aláyọ̀ àti láti le kọ́ ìdílé wa ní ìbámu pẹ̀lú ìlàkalẹ̀ Ọlọ́run. Mo gbàdúrà pé Olúwa Ọlọ́run yíò ràn wá lọ́wọ́ ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.


Ó ṣe pàtàkì fún wa láti mọ̀ pé láìsí ìpìlẹ̀ tí ó dára, a kò lè kọ́ ohun yòówù tí a ní ní ìpinnu. Láìsí ìpìlẹ̀ tí ó dára tí ó sì yè kooro, a kò lè kọ́ ìdílé wa. Ìdílé tí a bá sì kọ́ sórí ìpìlẹ̀ tí ko dára, yíò dà wò dandan ni. Níse ni yóò máa mì, irú ìdílé bẹ́ẹ̀ yóò ní ìdojúkọ ìṣubú. Níbo ni ò n kọ́ ìdílé rẹ lé lórí, ìyá wa?

**"Nítorí ìpìlẹ̀ mìírán ni ẹnìkan kò lè fi lẹ́lẹ̀ ju èyí tí a ti fi lélẹ̀ lọ, tí í ṣe Jésù Krístì."** 2 Kor 3:11

**"Bí ìpìlẹ̀ bá bàjẹ́, kí li olódodo yíò ṣe?"** Orin Dáfídì 11:3.

**FÚN ÈMI ÀTI ÌWỌ LÁTI LÈ KỌ́ ÌDÍLÉ WA, A NÍ LÁTI ṢE ÀWỌN OHUN MẸ́TA WỌ̀NYÍ**

1. Fi ìdílé rẹ lélẹ̀ lórí ìpìlẹ̀ tí ó dára tàbí kí o tún ìpìlẹ̀ rẹ kọ́. Báwo ni ìdílé rẹ se dúró sí?






2. Wá ọgbọ́n láti kọ́ ilé rẹ.

3. Kọ́ ilé rẹ.

**1. BÁWO NI ÌDÍLÉ RẸ ṢE YÈ KORO SÍ? FI ÌDÍLÉ RẸ LÉLẸ̀ LÒRÍ ÌPÌLẸ̀ TÍ Ó DÁRA TÀBÍ KÍ O TÚN ÌPÌLẸ̀ RẸ KỌ́.**

A ní láti kọ́ ìdílé wa lórí Jésù Krísti. Òun ni àpáta agbára. 1Kor 10:4c. Ní kíkọ́ ayé rẹ, ìdílé rẹ àti ìgbéyàwó rẹ, o gbọ́dọ̀ dúró kí o sì kọ́ ọ sórí Jésu tí í ṣe ìpìlẹ̀ ohun rere gbogbo. Òun ni ìpìlẹ̀ ohun rere gbogbo. Ó ṣe pàtàkì láti fi àyè gba àjọṣepọ̀ rẹ pẹ̀lú olùkọ́ ilé náà. Nígbànáà ni Olúwa yíò dunnú sí àjọṣepọ̀ rẹ pẹ́lú Rẹ̀, òun yíò sì ṣe tán láti pẹ̀lú rẹ ní íkọ́ idílé rẹ.

O ní láti kọ́lé lée lórí - Jésù. Òun ni ìpìlẹ̀ àti olùkọ́ ìdílé tí ó dára tí ò n fẹ́. Jẹ́ kí ó kọ́ ọ, tún kọ́, tàbí kí ó wọ ilé rẹ lágbàra fún ọ; kò tíì pẹ́, ó sì lè tún ìdílé rẹ̀ kọ́. O gbọ́dọ̀ kọ́lé lórí ìpìlẹ̀ tó yè koro tí í ṣe Jésù

Krístì, ẹni tí ó jẹ́ pé láìsí rẹ̀ o kò lè ní ìpìlẹ̀ mìíràn. Ìpìlẹ̀ rere àti tí ó yè koro ni àmúlò rẹ, Jésù Krístì fúnra rẹ̀ sì ni àmúlò fún aṣeyọrí nínú ayé àti ìdílé rẹ. Wíwá Ọlọ́run ni ọ̀nà àbáyọ fún ọ láti kọ́ ìdílé tí ó dára.

Àwọn òbí kan a máa pa irọ́, ó sì jẹ́ ìyọnu fún wọn pé àwọn ọmọ wọn náà npa irọ́. Àwọn kan n bá wọn kó owó jẹ níbi iṣẹ́, wọ́n sì n sunkún torí ìwà àwọn ọmọ wọn tó n hu irú ìwà bẹ́ẹ̀. Àwọn tí ó máa n bínú nkọ́, tí à sì tètè máa n ṣẹ̀, tí wọ́n wá n dá àwọn ọmọ wọn lẹ́bi nígbàkúgbà tí wọ́n bá ṣe bẹ́ẹ̀?

Òtítọ́ ọ̀rọ̀ tó wà níbẹ̀ ni wípé, o kò lè fún ènìyàn ní nnkan tí o kò ní. Ká sọ òtítọ́, a kò lè gan Ọlọ́run, ohun yòówù tí ènìyàn bá gbìn ni yóò ká. O máa n sọ ọ́ lóòrè kóòrè wípé ọkọ rẹ kìí sòótọ́, ìbéèrè mi ni pé, ìwọ́ ha n ṣọ ọ́ bí? Nínú ọkàn rẹ, dá ara rẹ lọ́hùn, ṣé ìwọ n sọ òtítọ́?



Àwa ni à n ṣe okùnfà àwọn ohun tó n ṣẹlẹ̀ lòdì ní àyíká wa. Mo mọ̀ wípé o mọ ìwé lọ́pọ̀lọpọ̀, ṣùgbọ́n báwo ni ọkàn rẹ ṣe mọ́ tó? Mímọ́ ọkàn rẹ ni ó le sọ bí agbára àti ore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run ṣe tóbi tí ó sì jinlẹ̀ sí nínú ayé rẹ̀.

Báwo ni ó ṣe mọ olùkọ́ ilé tóòtọ́ sí? Èyí ní í ṣe pẹ̀lú bí o ṣe lè kẹ́kọ̀ọ́ lábẹ́ rẹ̀, láti lè kọ́ ìdílé tìrẹ. "Bí Ọlọ́run kò bá kọ́ ilé náà, àwọn olùkọ́ nṣe lásán."

Báwo ni o ṣe jọ̀wọ́ ara rẹ fún Krístì sí, tí ò sì n ráhùn nípa àwọn ènìyàn tí ó yí ọ ká? Mo ní ìgbàgbọ́ wípé bí Ọlọ́run bá ti rí ààyè nínú ayé rẹ ni, ohun gbogbo ì bá ti bọ̀ sípò. Bóyá bí o bá bá Ọlọ́run làjà, Òun yíò fún ọ ní ọ̀rọ̀ ọgbọ́n láti sọ sí ọmọ rẹ nì tàbi ẹnìkejì rẹ (ọkọ).

Ìpìlẹ̀ wa pẹ̀lú Ọlọ́run ni ó le sọ nípa gbogbo ohun tí ó n ṣẹlẹ̀ ní àyìká wa. Bẹ́ẹ̀ni!! Mo mọ̀ wípé ohun gbogbo tàbí

púpọ̀ nínú àwọn ohun tí ó yí ọ ká ni ó n ṣe déédé. Ṣùgbọ́n ìwọ náà mọ̀ nínú ọkàn rẹ pé o kò tíì bá Ọlọ́run làjà ní àwọn ẹ̀ka ayé rẹ kọ̀ọ̀kan. Mo gbàdúrà wípe ore-ọ̀fẹ́ Rẹ̀ yóò tó fún gbogbo wa ni orúkọ nlá Jésù. Àmín.

**OHUN TÍ O GBỌ́DỌ̀ ṢE**






**A. Ṣe ìṣirò ohun tí yóò ná ọ**



Ní kíkọ́ ìdílé rẹ nínú Krístì, o gbọ́dọ̀ ṣe ìsirò ohun tí yíò ná ọ. Èyí ni pé, kínni àwọn ohun tí yíò ná wa láti jẹ́ krìstẹ́nì? O gbọ́dọ̀ kọ ayé àti iṣẹ́ rẹ sílẹ̀, nípa pé kí á má:

- Gba agbára ti ayé yìí. (Ilé ayé yìí jẹ́ ayé agbára, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ l'a sì nílò agbára láti tẹ̀síwájú àti láti ṣe àṣeyọrí). O nílò láti ṣe àwárí agbára tòótọ́ nípasẹ̀ agbára Ẹ̀mí Mímọ́ láti tẹ̀síwájú.
- Ṣe bí ayé tí n ṣe: Bíi gbígbé ìyàwọ́ pẹ̀lú agbára òkùnkùn,bíbí ọmọ nípa

bíbéèrè lọ́wọ́ ayé, níní ọrọ̀ nípa ṣíṣẹ́ṣó. Gbogbo èyí ni ọ̀nà búburú láti ṣe àkójọ.

- Ṣe ìfẹ́ inú wa lòdì sí ìfẹ́ Ọlọ́run ní gbogbo ẹ̀ká ayé wa; ṣíṣe ìfẹ́ Ọlọ́run gbọ́dọ̀ jẹ́ àfojúsùn tí ó jẹ ọ́ lógún.

**B. O gbọ́dọ̀ ni àfojúsùn**

Pinnu kí ore-ọ̀fẹ́ rẹ̀ kí ó bà lé ọ lórí, pinnu láti wọ ìjọbá ọ̀run. Pinnu láti má pàdánù ẹ̀mí rẹ fún èṣù, ẹni tí ó wà ní àyíká rẹ láti já ẹ̀mí rẹ gbà. Jọ̀wọ́, wà ní ìmúrasílẹ̀ kí o sì wà ní ìpapọ̀-ọkàn lórí irú ìpìlẹ̀ tí ò n fi lélẹ̀ nínú Krísti Jésù. Báwo ni o ṣe n rin ọ̀nà àjò rẹ lọ sí ọ̀run?

**D. Ránṣẹ́ pe onímọ̀ẹ̀rọ ayé rẹ̀, bí o ti ṣe n mọ ìpìlẹ̀ ilé náà.**

Pàápàá bí o ti ṣe n gbé ìgbésẹ̀ kọ̀ọ̀kan, mímọ bíríkì ìpìlẹ̀ náà ní ọ̀kọ̀ọ̀kan ní ohun tí ó n ṣe. Àwọn búlọ́ọ́kù tí à n mọ ni àwọn ìgbésẹ̀ tí à n gbé ní ìgbà tí à n kọ́ ìdílé wa, èyí tí ó wà ní oríṣi ìsọ̀rí. Bí àpẹẹrẹ, irú ilé-



ìwe tí àwọn ọmọ wa n lọ, jíjọ ní àpò àsùnwọ̀n kan, pípe àwọn mọ̀lẹ́bí láti wa tàbí láti ma wá ba yín gbé, irú ìgbéyàwó tàbí ìnáwó tí a fẹ́ ṣe fún ìgbéyàwó àwọn ọmọ, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Mímọ amọ̀ lé orí ìpìlẹ̀ wa ṣe pàtàkì. Èyí ni ó le sọ bí ilé náà yíò ti rí, **Òun nìkan ṣoṣo ni ó le ṣe àgbékalẹ̀ ilé aláyọ̀ fún ọ.** Ó ṣe pàtàkì kí o tẹ̀lé e láti ìbẹ̀rẹ̀ títí dé òpin.

O ní láti tẹ̀lé e dé ojú àmì, kí o sì gbọ́ ràn sí gbogbo ìkìlọ̀ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí onímọ̀- ẹ̀rọ.

Ìyá wa, ìwọ nìkan nínú ọgbọ́n rẹ kò lè dáa kọ́, Òun ni ayàwòrán àgbà. Ránṣe pe Ẹ̀mí Mímọ́ nítorí Ó wà lẹ́gbẹ̀ ẹ́ ọ̀dọ̀ rẹ.

**Àkíyèsí**

O lè ma sọ nínú ọkàn rẹ lọ́wọ́lọ́wọ́ wí pé o kò jọ àwọn tí kò mọ Ọlọ́run. Bẹ́ẹ̀ni, ọmọ Ọlọ́run ni. Ohun tí mò n sọ ni pé, bóyá tí o bá ti fi ìrẹ̀lẹ̀ àti ìkíyèsára ránṣẹ́ pè E, Òun tíí ṣe olùtùnú àti olùtọ́ni nlá, sínú gbogbo ẹ̀ka ayé rẹ ni, ayé rẹ̀, ìdílé rẹ̀ àti ìgbéyàwò rẹ yíò ti dára ju èyí lọ.

Ìyá wa, a kò le tan Ọlọ́run, Ó mọ̀ ọ́ ju bí o ti mọ ara rẹ lọ. Ó n rí gbogbo wa, bí o ti n làkàkà láti ni ayọ̀ ìgbéyàwó, èyí tí Òun ti gbé kalẹ̀ fún ọ láti ní fún ìní. Ìwọ ni o ni ayọ̀ rẹ, olùràpadà rẹ̀ Jésù Krístì ti fi fún ọ, ṣùgbọ́n èṣù n bẹ ní àyíká rẹ nígbà gbogbo, ó n jìjàkadì láti gbà á kúrò ní ọwọ́ rẹ. Mo gbàdúrà pé ìwọ yóò gbọ́n ju èṣù lọ pàápàá bí o ti n tẹ̀lé àwọn ìdarí àtọ̀runwá yìí ní orúkọ Jésù. Àmín.

**E. Ránṣe pe Ẹ̀mí Mímọ́, Olùrànlọ́wọ́ wa.**

A kò gba Ẹ̀mí Mímọ́ láàyè ní kíkún. Olúwa ti fún wa ní olùrànlọ́wọ́ tí ó le ràn wá lọ́wọ́ láti ṣ'àṣeyọrí nínú igbéyàwó wa. À n gbìyànjú, a sì n jà láti fẹ́ ẹnìkejì wa (ọkọ) pẹ̀lú agbára, okun àti ipá wa, ṣùgbọ́n Ẹ̀mí Mímọ́ nìkan ló le ràn wá lọ́wọ́.

Ohun tó mú kí Pétérù sẹ́ Jésù ni ẹ̀rù, Bíbélì sì sọ wípé nígbàtí Ẹ̀mí Mímọ́ bà lé Pétérù, ó ṣe tán láti kú fún Krístì.



Ọ̀pọ̀lọpọ̀ wa n wọn ìdúró wa nínú Ọlọ́run pẹ̀lú ìwọ̀n ẹ̀bùn Ọlọ́run nínú wa. Èso tí à n so ló ṣe pàtàkì. Nígbàmíràn ẹ̀wẹ̀, a máa n lérò wípé ìgbéyàwó wa gbọ́dọ̀ dára nítorí ẹ̀bùn tí a ní, rara. Ìrànlọ́wọ́ kan ṣoṣo tí a ní wà nínú Ẹ̀mí Mímọ́.

**ÈSO Ẹ̀MÍ MÍMỌ́**

Mo gbà ọ́ nímọ̀ràn nítòótọ́, pé kí o so èso ti Ẹ̀mí Mímọ́. Ó ṣe pàtàkì lọ́pọ̀lọpọ̀.

Àwọn èso wọ̀nyìí ṣe akójọpọ̀ irú ẹni tí o jẹ́ nípa ti ẹ̀mi àti nípa ti ara. Ẹni tí o jẹ́ sí Ọlọ́run Ẹlẹ́dàá rẹ àti sí gbogbo àwọn ènìyàn tí ó wà ní àyíká rẹ. Ìhùwàsí rẹ ni ó n darí rẹ láti kọ́ ayé rẹ̀ àti idílé rẹ dáradára lórí Krístì àpáta.

"**Ṣùgbọ́n èso ti Ẹ̀mí ni ÌFẸ́, AYỌ̀, ÀLÁÁFÍÀ, ÌPAMỌ́RA, ÌWÀ PẸ̀LẸ́, ÌSORE àti ÌGBÀGBỌ́.**" Galatia 5:22

Njẹ́ o ṣe àkíyèsí pé "ÌFẸ́" ni ó ṣe àkọ́kọ́ nínú gbogbo èso ti Ẹ̀mí Mímọ́?

Bíbélì nínú iwé Kọ́ríntìn kìn-ín-ní, orí kẹ̀tàlá, ẹsẹ̀ kìn-ín-ní dé ìkẹjọ (1Cor. 13:1-8) wípé:

**"Bí mo tilẹ̀ n fọ onírúurú èdè àti ti ángẹ́lì, tí èmi kò sì ní ìfẹ́, èmí dàbí idẹ tíndún, tàbí bí kínbálì olóhùn gooro."**

**"Bí mo sì ní ẹ̀bùn ìṣọtẹ́lẹ̀, tí mo sì ní òyé gbogbo ohun ìjìnlẹ̀, àti gbogbo ìmọ̀, bí mo sì ní gbogbo ìgbàgbọ́ tó bẹ́ẹ̀ tí mo le sí àwọn òkè nlá nípò, tí èmi kò ní ìfẹ́, èmi kò jẹ́ nkan."**

**"Bí mo sì n fi gbogbo ohun ìní mi bọ́ àwọn tálákà bí mo sì fi ara mi fún ni láti sun, tí èmi kò sì ní ìfẹ́, kò lí èrè kan fún mi."**

**"Ìfẹ́ a máa mú sùúrù, a sì máa ṣeun: ìfẹ́ kìí ṣe ìlara; ìfẹ́ kìí sọ̀rọ̀ ìgbéraga, kì í fẹ̀,"**

**"Kì í hùwà àìtọ́, kìí wá ohun ti ara rẹ̀, a kìí mú u bínú, bẹ́ẹ̀ ni kì í gbìrò ohun búburú; Kì í yọ̀ sí àìṣòdodo, ṣùgbọ́n a máa yọ̀ nínú òtítọ́."**



**"A máa farada ohun gbogbo, a máa gba ohun gbogbo gbọ́, a máa retí ohun gbogbo, a máa fàyàrán ohun gbogbo."**

**"Ìfẹ́ kìí yẹ̀ láí: ṣùgbọ́n bí ó bá ṣe pé ìsọtẹ́lẹ̀ ni, nwọn ó dópin; bí ó bá ṣe pé ẹ̀bùn ni, nwọn ó dákẹ́; bí ó bá ṣe pé ìmọ̀ ni, yíò di asán."**

Àwọn ẹ̀bùn ẹ̀mí yíò le dàgbà bí ó bá dàgbà **nínú gbòngbò ìfẹ́. Bí a ṣe n rí àwọn ọkọ wa kọ́ ni wọ́n ṣe rí. Bí ọkàn wa ṣe n rí àwọn ọkọ wa ni wọ́n ṣe rí ní ojú wa, torí pé a kò gba Ẹ̀mí Mímọ̀ láàyè láti ṣí wa lójú kí ó sì ràn wá lọ́wọ́.**

**Àdúrà**

Mo fẹ́ kí o béèrè lọ́wọ́ Ẹ̀mí Mímọ́ láti ràn ọ́ lọ́wọ́ láti àkókò yìí lọ. Àkókò agbára, ore-ọ̀fẹ́ àti ìfikúnni Ẹ̀mí Mímọ́ ni a wà yìí. Ó wà níhìn yìí láti ràn ọ́ lọ́wọ́, bí ó bá lè ránṣẹ́ pè. Ó ti ṣèlérí láti jẹ́ olùrànlọ́wọ́ wa, kò sì lé kùnà. Jẹ́ kí a gbàdúrà, ó n bẹ ní

ọ̀dọ̀ rẹ, pè é sínú ayé rẹ̀, Ó n bẹ nítòsí rẹ nísinsìnyí.

**f. Kíkọ́ ayé rẹ pẹ̀lú ìdánilójú àti ìgboyà**

- Gbé àwọn ìgbésẹ̀ tí ó ní kí o gbé.
- Ṣíṣẹ̀ pọ̀ pẹ̀lú rẹ̀ nínú àwọn ìdarí àti ìtọ́ni rẹ̀.
- Òun kò lè ṣìṣe, aláṣepé ni Òun.
- Òun kò le ṣì ọ́ darí, tẹ̀lé e. Olùdarí tó dára jùlọ ni, yóò sì darí rẹ síbi àṣeyọrí rẹ.

**a. Gbigbe nínú agbègbè Rẹ̀**

**"Ẹni tí ó jókò ó níbi ìkọ̀kọ̀ Ọ̀gá Ògo ni yío ma gbé abẹ́ òjìji Olódùmarè."** Orin Dáfdì 91:1.

A gbọ́dọ̀ máa gbé nínú ilé ní agbègbè èyí tí ìpìlẹ̀ tí ó dára tí ó sì yè kooro gbé wà. Ìbáré̩ ayé tó le jásí panṣágà ni a kò fi àyè gbà.

**2. WÍWÁ ỌGBỌ́N LÁTI KỌ́ ÌDÍLÉ RẸ**

Ọgbọ́n jẹ́ fífi àwọn ohun tí o mọ̀ sí ìṣẹ. **"Ìbẹ̀rù OLUWA ni ìpilẹ̀ṣẹ̀ ìmọ̀; ṣùgbọ́n aṣiwèrè gan ọgbọ́n àti ẹ̀kọ́."** Òwe 1:7



**"Ìbẹ̀rù OLUWA ni ìpilẹ̀ṣẹ̀ ọgbọ́n: àti ìmọ̀ ẹni mímọ́ li òye."** Òwe 9:10

O gbọ́dọ̀ ní ìmọ̀ ohun kan kí o tó le sọ̀rọ̀ nípa lílo ohun tí o mọ̀.

Ìbẹ̀rù Olúwa yóò yọrí sí ìmọ̀ (níní àwọn kókó ọ̀rọ̀), sí ọgbọ́n (lílo àwọn kókó ọ̀rọ̀ yìí sí ìgbé ayé). Nígbà náà ni ìwọ yiò kọ́ ilé rẹ tí ìwọ yóò sì ní àṣeyọrí.

Ní wíwá ìmọ̀ Ọlọ́run àti ti Bíbélì láti kọ́ ìdílé rẹ, o nílò láti ní ìbẹ̀rù Ọlọ́run. Láti ní ìmọ̀ fún aṣeyọrí àti àlùyọ, láti ní ìmọ̀ fún àlàáfíà àti ìrẹ́pọ̀ nínú ìgbéyàwó rẹ, o nílò láti ní ìbẹ̀rù Ọlọ́run.

- Máa ṣe ohun tí Jésù lè ṣe, kí ò sì kọ àwọn ohun tí kò lè ṣe sílẹ̀.
- Dà bi Jésù nínú gbogbo ìwà àti ìṣe rẹ.
- Fi ẹ̀dá Ọlọ́run hàn nínú ìṣesí rẹ.

Ìgbà tí o bá tó bẹ̀rù Ọlọ́run ni o ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ ìrìn àjò lọ sí ìlú ìmọ̀, kí á tó sọ ti ọgbọ́n níní. **Nítorí láìsí ìmọ̀, o kò lè ní ọgbọ́n. Bí o kò bá sì ní ìmọ̀ ohun kan, o kò lè kọ́ ohun náà**.

Nípa ọgbọ́n Ọlọ́run nìkan ni o le kọ́ ìdílé rẹ. O gbọ́dọ̀ wá ìmọ̀ Ọlọ́run fún àti kọ́ ìdílé rẹ. Nígbà tí o bá bẹ̀rù Ọlọ́run, ó túmọ̀ sí wípé o ti fi ìpìlẹ̀ lélẹ̀, èyí tí í ṣe wíwá ìmọ̀. Ó túmọ̀ sí pé o ti mo àṣírí àṣeyọrí, àlùyọ àti ìṣẹ́gun nínú ìdílé.

A sọ nípa ti àwọn agbẹ̀bí tí Ọlọ́run kọ́ ilé fún wọn nítorí wọ́n bẹ̀rù OLÚWA. "Ó sì ṣe, nítorí àwọn agbẹ̀bí náà bẹ̀rù Ọlọ́run, Òún sì kọ́ ilé fún wọn."

**ỌGBỌ́N**

Ìtumọ̀ ọgbọ́n ju pé kí á mọ ohun púpọ̀ lọ. Ó jẹ́ ìhùwà tí ó nípá lórí gbogbo ẹ̀ka ìgbé ayé. Ìpìlẹ̀ ìmọ̀ ni ká bẹ̀rù Olúwa.
Láti bẹ̀rù Ọlọ́run túmọ̀ sí pé:

- Bíbu ọlá àti ọ̀wọ̀ fún Ọlọ́run
- Gbígbé nínú ọwọ́ agbára rẹ̀
- Gbígbọ́ràn sí ọ̀rọ̀ rẹ̀ (ní kíkún)

Kíkórìra ibi, ìgbéraga àti ìrera. Òwe 8:13



Láti jọba lórí àwọn elòmíràn, o gbọ́dọ̀ lè jọba lórí ayé ara rẹ. O kò lè jọba lórí ayé rẹ dáradára bí o kò bá tẹ̀lé ìlànà àti òfin láti ní ọgbọ́n. Láti ní ọgbọ́n, o gbọ́dọ̀ mòye, ìmòye sì ni láti ní ìmọ̀.

*O gbọ́dọ̀ bẹ̀rù Olúwa, fún ọ láti ní ìmọ̀.

Ó ṣe pàtàkì fún ọ láti lo ọgbọ́n Ọlọ́run nínú ìdílé, bí bẹ́ẹ̀ kọ́, ìgbéyàwó rẹ yíò jìyà. O kò sì lè ní ọgbọ́n Ọlọ́run láìní ìmọ̀ Rẹ̀.

Bíbélì sọ pé "Ìbẹ̀rù Ọlọ́run ni ìpilẹ̀sẹ̀ ìmọ̀", nítorí náà, bẹ̀rù Ọlọ́run.
**Àkíyèsí: Èyí jẹ́ ohun kékeré tí yíò ná ọ láti ṣe àṣeyọrí àti láti kọ́ ìdílé rẹ. Sá ti gbọ́ràn. Nínú ìgbọ́ràn rẹ ni ayọ̀ rẹ wà.**



Nínú ìdílé tàbí ìgbéyàwó gbogbo, a gbọ́ dọ̀ fi ìfẹ́ hàn, ìfijì àti ìhùwà tí ó pegedé. Nígbà tí a bá ti yan ọ̀nà Ọlọ́run, Òun yóò fún wa ní ọgbọ́n. Ọ̀rọ̀ Rẹ̀, Bíbélì n darí wa láti gbé ìgbé ayé tí ó tọ́, ní ìbáṣepọ̀ títọ́ àti láti gbé àwọn ìgbésẹ̀ tí ó tọ́. Èyí túmọ̀ sí pé láìsí ìbẹ̀rù Ọlọ́run nínú rẹ, o kò lè kọ́ ilè rẹ yọrí.

Ní kúkúrù, líàsí ìbẹ̀rù Ọlọ́run:

- O kò lè  ní àṣeyọrí.
- Kò sí rere tabí ìgbéyàwó tí o ládùn.
- Kò sí ìdílé aláyọ̀ tí ó ní àṣeyọrí.

Mo rọ̀ wá pẹ̀lú ìbámu pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run pé kí á wá ọgbọ́n láti kọ́ ìdílé wa kí á sì ṣe ìdílé wa ní ìbùgbé Ọlọ́run.

**APÁ KEJÌ Òwe 1:7**

7b-: "sọ pé: "Ṣùgbọ́n àwọn aṣiwèrè gan ọgbọ́n àti ẹ̀kọ́."

7b-: Aṣiwèrè (gẹ́gẹ́ bí Bíbélì ti darí rẹ̀)



- Aṣiwèrè ni ì máa n ṣe bí ẹni tí ó mọ ohun gbogbo.
- Ẹnikẹ́ni tí ó bá ni èrò tí kò fidí múlẹ̀ nípa ohun gbogbo.
- Ẹni tí ọkàn rẹ̀ sẹ̀ sí ohun titun.
- Ẹni tí ó bá kọ ìbáwí.
- Ẹni tí ó bá kọ̀ láti kẹ́kọ̀ọ́.

**Àkíyèsí:** Máṣe jẹ́ ẹni tí ó mọ ohun gbogbo, máa gbọ́ ìmọ̀ràn àwọn èlòmíràn pàápàá àwọn tí ó mọ̀ ọ́ dájú tí ó sì lè fún ọ ní ìmọ̀ràn tí ó péye.

Bíbélì pè ọ́ ní aṣiwèrè tí o bá kọ ọgbọ́n àti ìtọ́ni. Nígbàtí èṣù, baba gbogbo aláìsòótọ́ bá tilẹ̀ tàn ọ́ sínú àìní ìbẹ̀rù Ọlọ́run, nígbatí òo kò bá ti ní ìbẹ̀rù Ọlọ́run nínú rẹ mọ́, nígbàtí o bá ti n mọ̀ọ́ mọ̀ dá ẹ̀ṣẹ̀, tì ò n mọ̀ọ́mọ̀ ṣe àgbèrè àti panṣágà. Nígbà mììràn ẹ̀wẹ̀, ò n sun ẹkún fún àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, ṣùgbọ́n o tún mọ́ ọ̀mọ̀ padà sínú rẹ̀, Bíbélì pè ọ́ ni aṣiwèrè,

nítorí ó yẹ kí o mọ̀ pé, a kò lè gan Ọlọ́run. Òun ni Ọlọ́run, aṣẹ̀dá ọkàn rẹ. Oun ni ó dá ọ̀run àti ayé:

A kò lè tàn An; Oun ni Ọlọ́run tí ó mọ ohun gbogbo.

Ó jẹ́ ohun tí ó ṣe iyebíye láti mọ̀ wípé kíkọ́ láti ní ìbẹ̀rù Ọlọ́run lè mú kí ènìyàn pàdánù ẹ̀mí rẹ̀ nítorí irú ayé bẹ́ẹ̀ kì yíò ní ìtumọ̀.

**Ewu tó wà nínú kíkọ̀ láti wá Ọgbọ́n Ọlọ́run**
Òwe 1:24-33

24. "Nítorí tí èmí pè, tí ẹ̀yín sì kọ̀; tí èmí na ọwọ́ mi, tí ẹnìkan kò sì kàá sí;

25. Ṣúgbọ́n ẹ̀yin ti ṣá gbogbo ìgbìmọ̀ mi tì, ẹ̀yin kò sì fẹ́ ìbáwí mi:

26. Èmi pẹ̀lú ó rẹ́rìn-ín ìdàmú yín; èmi yóò ṣe ẹ̀fẹ̀ nígbàtí ìbẹ̀rù yín bá dé;

27. Nígbàtí ìbẹ̀rù yín bá dé bí ìjì, àtí ìdàámú yín bí àfẹ́yíká-ìjì; nígbàtí wàhálà àti àrodun bá dé si yín.



28. Nígbànáà ni ẹyin ó képè mí, ṣùgbọ́n èmi kì yíò dáhùn; wọn ó ṣàfẹ́rí mi ní kùtùkùtù, ṣùgbọ́n wọn kì yíò rí mi:

29. Nítorí tí wọ́n kórìra ìmọ̀, wọn kò sì yan ìbẹ̀rù Olúwa.

30. Wọn kò fẹ́ ìgbìmọ̀ mi: wọ́n gan gbogbo ìbáwí mi.

31. Nítorínà ni wọ́n ó ṣe ma jẹ nínú èrè ìwà wọn, wọn ò sì kún fún ìmọ̀kímọ̀ wọn.

32. Nítorípé ìrọra àwọn aláìmọ̀kan ni yíò pa wọ́n, àti àlááfíà àwọn aṣiwèrè ni yíò pa wọ́n run.

33. Ṣùgbọ́n ẹnikẹ́ni tí ó bá fetí sí mi yíọ́ ma gbé láìléwu, yíò sì farabalẹ̀ kúrò nínú ìbẹ̀rù ibi.

Bí ìwọ kò bá bẹ̀rù Rẹ̀, dájúdájú, ìwọ yíò ṣẹ̀ síi.

**"Ṣùgbọ́n ẹnití ó ṣẹ̀ mí, ó ṣe ọkàn ara rẹ̀ níkà: gbogbo àwọn tí ó kórìra mi, wọ́n fẹ́ ikú."** Òwe 8:36.

**Ànfàní  yíyàn láti bẹ̀rù Olúwa**

- Àwọn ẹbí rẹ yíò máa gbé ní àlááfíà. "Ṣùgbọ́n ẹnikẹ́ni tí ó bá fetísími yíò ma gbé láìléwu, yíò sì farabalẹ̀ kúrò nínú ìbẹ̀rù ibi." Òwe 1:33.
- Ìwọ yíò ní ìmọ̀ran rere àti ọgbọ́n tí ó yẹ̀ láti kọ́ ìdílé rẹ. "Tèmi ni ìmọ̀ àti ọgbọ́n tí ó yè: èmi li òye, èmi li agbára." Òwe 8:14
- Òun yíò fún ọ ni okun láti mòye ọkọ àti àwọn ọmọ rẹ. Òwe 8:14b.
- Ìwọ yíò ṣe àkóso, o ó sì jọba ayé rẹ. Òwe 8:15-16. "Nípasẹ̀ mi li ọba n ṣe àkóso, tí àwọn olórí sì n lànà òtítọ́. Nípasẹ̀ mi li àwọn ìjòyè nṣolórí, àti àwọn olótìtọ́, àní gbogbo àwọn onídajọ́ ayé."
- Òwe 8:17a, "Mo fẹ́ àwọn tí ó fẹ́ mi", bí àpẹẹrẹ, obìnrin tí ó bá fẹ́ràn ọkọ rẹ̀ yíò bẹ̀rù rẹ̀.

**Àkíyèsí:** Bí o bá fẹ́ràn Ọlọ́run, ìwọ yíò bẹ̀rù rẹ̀. Bí o bá fẹ́ Ọlọ́run nípa bíbẹ̀rù Rẹ̀,



Òun yíò fẹ́ràn rẹ, bí Ọlọ́run bá sì ti fẹ́ràn rẹ, kò sí ohun tí kò lè ṣe fún ọ.

**"...èmí sì ti fẹ́ ọ, nítorí náà èmi yó fi ènìyàn rọ́pò rẹ, àti ènìyàn dípò ẹ̀mí rẹ."** Isaiah 43:4c.

Ìwọ yíò ní ọrọ̀ àti ọlá, ọrọ̀ dáradára àti ọ́dodo ni ìwọ yíò ní. "Ọrọ̀ àti ọlá mbẹ lọ́wọ́ mi, àní ọrọ̀ dáradára àti òdodo," Òwe 8:18.

Òun yíò mú kí o jogún ìní, yíò sì kún ìṣura rẹ.

**Ìmọ̀ràn/Ìparí**

Òwe 1:8, n rọ̀ ọ́ láti ,"gbọ́ ìtọ́ni Ọlọ́run baba rẹ àti pé kí o má ṣe kọ òfin ìyá rẹ," gbọ́ bí Ẹlẹ́dà á rẹ ti n pè ọ́ nísinsìnyi. Ó leè gba ẹni yòówù tí ó bá gbọ́. Jọ̀wọ́ ara rẹ̀ fún un, ó le gbà ọ́ kí ó tú ọ sílẹ̀.

"Èrè mi ta wúrà yọ nítòótọ́, ju wúrà dáradára lọ: àti ọrọ̀ mi ju fàdákà àṣàyàn lọ." Òwe 8:19.

Yíyàn láti bẹ̀rù Olúwa ní èrè ju èrè yòówù tí o lè ní lọ́kàn láti rí níbòmíràn lọ. Kò ṣe é fi wé wúrà. Látàrí kíkọ́ ilé rẹ, ànfàní rẹ̀ kò ṣe é fi wé wúrà. Mo gbàdúrà pé Olúwa Ọlọ́run yíò ràn wá lọ́wọ́ ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.

3. **KỌ́ ÌDÍLÉ RẸ**

- Àjùmọ̀ ní dúkìá papọ̀ ṣe pàtàkì. Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run wí nínú Gen 2:25 pé "...àwọn méjèèjì sì wà ní ìhòhò, àti ọkùnrin náà àti obìnrin rẹ̀, wọn kò sì tijú.
- Ṣìṣẹ́ takuntakun, ṣe ìtọ́jú ọkọ àti àwọn ọmọ rẹ, se oúnjẹ aládùn tí ó sì ṣara lóore. Obìnrin rere, Òwe 31:10-31
- Múra dáradára, níwọ̀ntúnwọ̀nsí àti ní mímọ́. 1Tim 2:9, 1Pet 3:3
- Máa fèsì pẹ̀lú ọ̀rọ̀ rere kí ò sì máa fi ìmoore hàn. Òwe 15:1, 26b



- Jẹ́ àwòkọ́ṣe rere fún àwọn ọmọ rẹ. Òwe 31:28
- Ìjọ̀wọ́ ara ẹni lótitọ́ àti ní kíkún náà wà pẹ̀lú fífi gbogbo ohun ìní rẹ mọ ọkọ rẹ, bí àpẹẹrẹ, owó rẹ. Efesù 5:22.
- Jẹ́ kí ilé àti àyíká rẹ máa mọ́ tónítóní, jẹ́ onímòtótó: nítorí ìmọ́ tótó borí àrùn mọ́lẹ̀, kí á má baà lọ sí ilé ìwòsàn lóòrèkóòrè.
- Yan àwòkọ́ṣe to ní ẹwà Krístì - Kristíẹ́nì. Irú ẹni bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ ẹni tí ó dàgbà ju ni tàbí kéré sí ni lọ́jọ́ orí.
- Jẹ́ ohun èlò tí n kọ́, ti sì n ṣe àtúnṣe.
- Jẹ́ ohun èlò tí n rannilọ́wọ́.

Mo gbàdúrà pé Olúwa Ọlọ́run yíò fún wa ní ore-ọ̀fẹ́ láti tẹ̀lé ọ̀nà Rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ti n darí wa láti kọ́ ilé wa ní orúkọ Jésù. Àmín.

## ORÍ KEJÌ

# ONÍWÀRERE ADÉ ORÍ ỌKỌ RẸ̀

**"Obìnrin oníwàrere li adé orí ọkọ rẹ̀: ṣùgbọ́n èyí tí n dójú ti ni dàbí ọyún nínú egungun rẹ̀",** bẹ́ẹ̀ ni Bíbélì wi nínú iwé Òwe 12:4.

Gẹ́gẹ́ bí olùtọ́ni tí ó wà lábẹ́ àkóso, n kò ní fún ọ ní ohunkóhun tí a kò fi fún mi tàbí darí mi. N kò ní kọ ohunkóhun tí Ẹ̀mi Mímọ́ Ọlọ́run ò fún mi ní ìmísí rẹ. N kò sì ní sọ ohun tí a kò fi sí mi lẹ́nu láti sọ, nkò sì ní fi omi la ọ̀rọ̀ ààyè rẹ̀ láti lè bá ìgbé ayé ẹnikẹ́ni mu. Nípa ore-ọ̀fẹ́ rẹ̀, màá sọ ní òkodoro, mo sì gbàdúrà pé èròngbà ẹni tí ó rán mi yíò wá sí ìmúṣẹ nínú ayé wa lórúkọ nlá Jésù. Àmín

Ó jẹ́ dandan fún ọ láti mọ̀ wípé, bí a kò bá kún nínú ẹ̀mí, èṣù yíò ma sọ̀rọ̀ sínú ọkàn wa ní gbogbo ìgbà tí ìyípadà bá wà nínú ìbáṣepọ̀ wa pẹ̀lú ọkọ wa.



"Obìnrin oníwà rere ni adé orí ọkọ rẹ̀," gbogbo wa la sì mọ̀ wípé adé jẹ́ ìbòrí: ó n bù kún ẹwà orí. Ó lè jẹ́ èyí t a fi wúrà ṣe tàbí ohun iyebíye mìíràn.

Bíbélì n sọ wípé àwa gẹ́gẹ́bí obìnrin, àwa ni wúrà àti ohun iyebíye nínú aye ọkọ wa. Àwa ni à n mú ayé wọn jẹ́ pàtàkì. Aya ni ó jẹ́ ohun àbò fún ọkọ rẹ̀, òun ni okun ọkọ rẹ̀ ní ti wípé, ó n gbàdúrà, ó sì n ṣìpẹ̀ fun ní ìgbà gbogbo. Òun ni ẹwà ọkọ rẹ̀, òun ni ó dúró bí ẹwà nínú ayé ọkọ rẹ̀, kí ọkọ rẹ̀ bà lè wu ni dára, kí ó sì ṣe é wò. Nígbàtí àwọn ènìyàn bá n pe ọkọ rẹ ní orúkọ tí ó dára tí ó sí dàbi Ọlọ́run, òun ni ó wà nídì rẹ̀.

Adé orí jẹ́ àmì ìṣàkóso, ó n sọ̀rọ̀ ìṣàkóso sí ọkọ rẹ. (Ìyá wa, gbọ́ èyí, òun kọ́ ni orí ọkọ rẹ, rárá o, ọkọ ni orí). Ìgbé ayé tirẹ ni ó n fi ìṣàkóso ọkọ rẹ hàn, ìwà rẹ sì n fi hàn pé ẹnikan n ṣe àkóso lórí rẹ; nínú ìmúra rẹ, ìrísí rẹ, ìsọ̀rọ̀sí rẹ àti ìhùwà rẹ, a ó ri bí o bá jẹ́ adarí lábẹ́ ìṣàkóso Olúwa wa Jésù Krístì nípasẹ̀ ọkọ rẹ tàbí bẹ́ẹ̀ kọ́.

Adé jẹ́ àmi "ogó", nítorí nàà òun ni ògo ọkọ rẹ nípa pé òun ni ì n sọ bí o ti n ṣe dáradára sí. 1Kor. 11:7c, "sùgbọ́n obìnrin ní í ṣe ògo okùnrin." Kí ọkọ rẹ tó le ṣe rere láyé, láti ṣ'àṣeyọrí níí ṣe pẹ̀lú ìwà rẹ, bí o ṣe mọ ohun tó yẹ kí o ṣe àti èyì tí kò yẹ fún ọ láti ṣe. Rántí ọ̀rọ̀ tí wọ́n máa n sọ, mo sì lè sọ fún ọ pé kìí ṣe ọ̀rọ̀ ẹnu lásán wípé "lẹ́hìn ọkùnrin tí ó ṣe àṣeyọrí, obìnrin kan mbẹ̀." Ọkùnrin ọlọgbọ́n nìkan ni ó le mọ àwọn nkan wọ̀nyí kí ó sì tẹ̀lé e; kí ó tọ́ jú aya rẹ̀ láti jẹ́ ohun èlò sí ọlá àti ògo fún ayé òun tìkara rẹ̀.

## ÌWỌKỌ́ NI ỌLỌ́RUN RẸ̀"

N ò sọ wípé ìwọ ni Ọlọ́run ọkọ rẹ láti sọ bí ọjọ́ ọ̀la rẹ̀ yíó ti rí. Ohun tí mò n sọ ni wípé, Ọlọ́run ti fi ọjọ́ ọ̀la rẹ̀ lé ọ lọ́wọ́. Ó wá kù sọ́wọ́ rẹ láti ṣe é bí o ti fẹ́, bóyá o ó jẹ́ kí ìdẹwò àti àdánwò aye yìí kí ó ṣì ọ́ darí ... àti pé njẹ́ o tilẹ̀ mọ̀ pé àwọn ọmọ rẹ le ṣì ọ́ darí nípa pínpín ìfẹ́ ọkọ rẹ àti ìtójú rẹ̀ pẹ̀lú àwọn ọmọ rẹ?



Ọkọ rẹ kìí ṣe ọmọ rẹ̀, ọmọ rẹ kìí ṣe ọkọ rẹ. O ní láti mọ̀ kí o sì gbà bẹ́ẹ̀. Ó ṣe pàtàkì kí o fi ọkọ rẹ ṣe àkọ́kọ́ kí ó tó kan àwọn ọmọ rẹ̀. Ó di ìgbà tí o bá rí ọkọ rẹ̀ bí àkọ́bí ọmọ rẹ kí o tó le tọ́jú rẹ̀ ní ìbámu pẹ̀lú ètò Ọlọ́run.

Adé jẹ́ àmì "ẹwà": Ó wà nínú ilé rẹ láti bu ẹwà kún ayé rẹ. Mo mọ̀ wípé o ó wípé ọkọ tìrẹ yàtọ̀, ṣùgbọ́n ta ni ó sọ fún ọ bẹ́ẹ̀? Ìdí rẹ̀ ní pé o kò fẹ́ ọkọ ẹlòmíràn, bẹ́ẹ̀, èyí kì yíò jẹ́ ìpín rẹ̀ ní orúkọ nlá Jésù, Àmín.

Ọkọ rẹ kò burú ju ti ọ̀rẹ́ rẹ nínú ìjọ lọ tàbí ní ibi iṣẹ́ lọ, tàbí tí àbúrò/ẹ̀gbọ́n rẹ. Ohun tí ó ní i ṣe pẹ̀lú èyí ni bí o ṣe n tọ́jú tìrẹ sí. Ìwà àti ìmọ àti tọ́jú ọkọ rẹ jẹ́ ìdí tí o ṣe nka ìwé yìí lónìí; la ṣe n kọ́ wa ní àwọn orìṣirìṣi ọ̀nà láti tẹ̀lé tàbí múlò láti ní ìgbeyàwó tí ó gún régé. Mo lo ọ̀rọ̀ yìí, "ìgbéyàwó tó gún régé" nítorí pé ìwọ gẹ́gẹ́ bí obìnrin ni o ní iṣẹ́ láti ṣe, láti mú kí ìdíle aláyọ̀ tí o ṣàfẹ́rí wá sí ìmúṣẹ.

**Àkíyèsí:** Ọ̀rọ̀ kan wà wípé: "àwa méjèèjì ni yíò mú kí ó ṣiṣẹ́", ṣùgbòn ìyá wa, ṣé o

gbà pẹ̀lú mi wípé o kò le fi agídí mú ọkọ rẹ láti ṣiṣẹ́ pẹ̀lú rẹ kí ìgbéyàwó yín le ṣiṣẹ́? Ó sì gbọ́dọ̀ ṣiṣẹ́, àbí kìí ṣe ibi tí à n lọ nìyẹn ní?

"Ìgbéyàwó mi gbọ́dọ̀ s'àṣeyọrí"

Nítorí náà, àdúrà ìṣìpẹ̀ wa nìkan ló lè mú kí o ṣe ipa tìrẹ, láti mú kí ó bá ọ ṣiṣẹ́ tàbí kí ìwọ siṣẹ́ pẹ̀lú rẹ̀ láti mú kí ilé rẹ wu ni.

Ìyá wa, bí o bá le ṣe èyí, mo fi dá ọ lójú pé ìwọ yíò ní ìdílé aláyọ̀ tí o ṣàfẹ́rí. Ṣe àkíyèsí wípé, òun ni orí, ṣùgbọ́n obìnrin ni adé orí. Efésù 5:23b.

Ìwọ ni ẹwà àti ààbò orí náà. Nítorí náà gẹ́gẹ́ bí adé orí, a wà níbẹ̀ láti da ààbò bò àti láti sin orí náà. Báwo ni a ó ṣe sìn tí a ó sì dáàbò bo orí náà gẹ́gẹ́ bí adé orí? A ní láti dá àbò bo wọ́n l'ẹ́mì í àti ní ti ara. A kìí bá orí du nkan, nítorí náà, a gbọ́dọ̀ tẹríba. Éfésù 5:23b, "gẹ́gẹ́ bí Krístì tí í ṣe orí ìjọ ènìyàn rẹ̀," a ní láti mọ̀ pé ọkọ wa gẹ́gẹ́ bí orí wa kò ṣé bá du nnkan, pàápàá gẹ́gẹ́ bí ìṣe-orí Krístì lórí ìjọ kò ṣe é dù.



Éfésù 5:22a, Ẹ̀yin aya, ẹ máa tẹríba fún àwọn ọkọ yín, gẹ́gẹ́ bí fún Olúwa." Nṣe ni a ní láti tẹríba pátápátá láì sí ìbéèrè àti ìgbónilẹ́nu pẹ̀lú rẹ̀. Èyi ni ìdí tí ó fi ṣe pàtàkì pé kí á máa gbàdúrà fún wọn láti má ṣì wá darí. A gbọ́dọ̀ rí wọn bí "Ọlọ́run kékeré" títí dé ìwọ̀n tí ọkọ rẹ yíò sọ fún ọ pé "dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run pé o ní ọkọ."

Kíyèsí pé eléyìí kì í ṣe nípa bóyá o lọ́rọ̀ tàbí o kúṣẹ̀ ẹ́. Bí ìgbéyàwọ́ rẹ kò bá ṣiṣẹ́ nígbàtí o jẹ́ akúṣẹ̀ tàbí nígbà tí o wà ní ìwọ̀nba, jẹ́ kí ó yé ọ wípé kò le è ṣàṣeyọrí bí o bá di ọlọ́rọ̀ tán. Ọrọ̀ kò lè jẹ́ àṣírí ilé aláyọ̀ lái, yíò kàn tún ìbànújẹ́ àti ìkorò gbé kalẹ̀ ni.

## ÀṢÌṢE TÍ ÒPÒ OBÌNRIN N ṢE, Ẹ JẸ́ KÍ Á KẸ́KỌ̀Ọ́ LÁRA RẸ̀

Àwọn obìnrin kan a máa sọ wípé "kò ní owó, kínni obìnriin mìíràn fẹ́ máa wá lára rẹ̀?" Tani ó sọ bẹ́ẹ̀ fún ọ?

Ọkọ rẹ le má jọ ẹ́ lòjú, ìyá, ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀lọpọ̀ obìnrin n bẹ lóde tó jẹ́ pé wọ́n

kàn sá fẹ̀ ẹ́ kí á mọ ọkùnrin mọ́ wọn ni; èyí lásan ti tán ìṣòro wọn. Àtí pé, ìyá, o ti ju adé orí rẹ (ọkọ rẹ) síta fún wọn nítorí pé o gbàgbọ́ pé kìí ṣe olówó tabua.

Njẹ́ o tilẹ̀ mọ̀ wípé àwọn obìnrin kan wà tí a tí "rán láti ọ̀dọ̀ èṣú wá" láti gba ayọ̀ ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìdílé, bẹ́ẹ̀ o wà níbí, o n ju adé orí tìrẹ kiri.

O n jẹun nígbàkugbà tí ebi bá n paá, níbikíbi, nítorí pé ìyàwó rẹ kò ní se oúnjẹ tó dára fún un. Oúnjẹ tí ó dára l'ásìkò kò di ìgbà tí o bá di ọlọ́rọ̀. Arábìnrin, o lè fi ọgbọ́n lo àwọn ohun tí o ní pẹ̀lú ìrètí wípé yíò dára lọ́jọ́ kan.

Ìyá wa, bí a bá sọ pé a ò lè f'ìfẹ́ lo nnkan tí ó wa lọ́wọ́ báyìí, ohun gbogbo yíò ti bàjẹ́ kí owó tàbí ọrọ̀ tó dé. Nítorí náà, ẹ jẹ́ kí á tọ́ju wọn báyìí, ní ìrètí pé nígbà tí àkókò tó dára bá dé, a ó lè gbádùn rẹ̀ papọ̀. Àmín.



## ÌJẸUN PỌ̀

Jíjẹun papọ̀ jẹ́ ohun kan gbọ́gì tí ó máa n mú ìsopọ̀ rere wá. Èyí yíò jẹ́ kí ìgbéyàwó rẹ ní àṣeyọrí, yíò sì jí ìsopọ̀ yín, ìfẹ́ yín àti ìfàsí ọkàn yín dìde. Nígbàtí ó bá ti mọ́ yín lára, yíò tètè wá sí ilé nítorí tí ó mọ̀ wípé ìyàwó òun kì yíò jẹun láìrí òun.

Ìyá wa, ẹ jọ̀wọ́ ẹ má sọ pé "lẹ́hìn ọmọ mélòó"? Ohun tí ẹ̀ n sọ náà nìyẹn, tí kò sí gbé ìgbéyàwó yín ró. Ẹ gbìyànjú èyí, ó ti ṣiṣẹ́ fún ọ̀pọ̀, ó dá mi lọ́jú wípé tìrẹ kì yíò yàtọ̀, pàápàá bí ó ti dàbí ẹni pé ó rọrùn, gbìyànjú rẹ̀.

## MÁ JẸ̀ KÍ WỌ́N ṢÌ Ọ́ DARÍ

Njẹ́ o mọ̀ wípé, àwọn obìnrin kan wà, wọ́n máa n ṣe "akọ" nígbàtí wọ́n bá n gbàdúrà tí wọ́n sì rí ìdáhùn, bóyá nípa ti ẹ̀mí tàbí ní ti ara. Wọn ò ní tètè gbá ọkọ wọn mú. Wọn ó ma sọ wípé "kí n má ba à dàbí òmùgọ̀ tàbí kí ó má mú mi ní ọ̀pọ̀", ó mà ṣe o, àànú rẹ ṣe mí.

## GBÍGBE NÍ Ọ̀TỌ̀Ọ̀TỌ̀

Irú àwọn ènìyàn tí àánú wọn ṣe mí púpọ̀ jù ni àwọn tí wọn kò gbé papọ̀. Wọ́n fi ipa ọ̀nà sí ọ̀run sílẹ̀ fún ohun ti ayé, bí àpẹẹrẹ, wọn n ṣiṣẹ́ ní Àbújá, wọ́n fi ọkọ wọn sílẹ̀ ní ìlú mìíràn tàbí ní orílẹ̀èdè mìíràn. Láì lákàsí àwọn obìnrin tí ọ̀tá tàbí èṣù ti fi iṣẹ́ rán. Ò n sọ wípé "bóyá o wà níbẹ̀ tàbí o kò sí níbẹ̀, kò sí ìyàtọ̀."

Ìyá wa, kí ló dé tí o fi n sọ bẹ́ẹ̀? Tí kò bá ti ní ìyàtọ̀, a jẹ́ wípé o kò ní àwọn àmúyẹ obìnrin oníwà-rere.

## MỌ ÀWỌN OHUN ÀKỌ́ṢE RẸ

À n ṣiṣẹ́ láti òwúrọ̀ títí di àṣalẹ́, à n ṣe iṣẹ́ ilé, à n tajà tàbí ṣiṣẹ́ ní Ọ́fíìsì, kódà à tún lọ sí àwọn ìsìn inú ìjọ. Ṣùgbọ́n ṣé o mọ̀ wípé àwọn obìnrin kan yíò ṣe àwọn nnkan wọ̀nyí sí ìkùnà ilé aláyọ̀ tí wọ́n ṣàfẹ́rí? Mo gbàdúrà wípé, o kò ní ṣiṣẹ́ lásán, ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.

Ohun àkọ́ṣe wa ni àdúrà ìṣìpẹ̀ fún ọkọ wa àti àwọn ọmọ wa. Kìí ṣe láti máa ṣiṣẹ́



ní gbogbo ìgbà, kí á ba à lè fi ààyè sílẹ̀ láti gbàdúrà bóyá ní ojúmọmọ tàbí òru. Njẹ́ o mọ̀ wípé Ọlọ́run fún wa ní ìlọ́po méjì oreọ̀fẹ́ tí Ó fún àwọn ọkùnrin? Òun yóò fi okun fún ọ ní orúkọ nla Jésù. Àmín.

## FI WỌ́N SÍ ÀÀYÈ WỌN

Ọba ni wọ́n, àwa bí adé orí yẹ́ kí á jẹ́ kí orí wa (ọkọ) jẹ́ pàtàkì. Ọba yíò ní ìrònú wípé òún jẹ́ pàtàkì nítorí adé tí ó dé sórí, àbí bẹ́ẹ̀ kọ́? Ojúṣe rẹ ni láti jẹ́ kí ọkọ rẹ jẹ́ ẹni pàtàkì, bí apẹẹrẹ, nípa bí a ti máa n kí wọn tọ̀wọ̀tọ̀wọ̀ àti àwọn orúkọ ìkẹ́ tí à n fún wọn. Mú wọn lò fún ọkọ rẹ̀, jẹ́ kí ó ṣe yẹ̀yẹ́ wípé, "ha! Ṣé ohun tí a ṣẹ̀ṣẹ̀ kọ́ ọ lèyí", kí ìwọ náà fi s'àwàdà wípé, "bẹ́ẹ̀ ni o, ọkọ mi". Tẹ̀síwajú nínú rẹ̀, má jẹ̀ kí ó dàbí ẹ̀gàn. Yíò mọ́ ẹ̀yin méjèèjì lára ìgbéyàwó yín yíò sì ní àmì. Àmin.

Efésù 5:24, "Nítorí náà gẹ́gẹ́ bí ìjọ tí tẹríba fún Krístì, bẹ́ẹ̀ sì ni kí àwọn aya kí ó máa ṣe sí ọkọ wọn lóhun gbogbo." Bíbélì sọ wípé, ní ohun gbogbo, ní ìtẹ́ríba

fún ọkọ rẹ̀; pẹ̀lú ara rẹ, (ìbálòpọ̀), ìṣúná àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Nígbàtí o bá n ra nnkan fún wọn, sọ̀rọ̀ adúra ohun rere sí àwọn nnkan náà, má kàn fún wọn bẹ́ẹ̀. Agbára nbẹ nínú ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ tí o bá sọ pẹ̀lú ìbámu ọ̀rọ̀ Ọlọ́run.

Òwe 12:4b, "ṣùgbọ́n èyí tí n dójú ti ni dàbíọ̀yún nínú egungun rẹ," èyí nì dàbí wàhálà tàbí ẹrù fún ọkọ rẹ̀. Àdúrà mi ní pé èyí kòò ní jẹ́ ìpín rẹ ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.

Ní àkọ́tán, mọ̀ wípé oríṣiríṣi adé ni ó wa. "Adé àlááfíà". Efésù 4:14a sọ wípé "Jésù Krístì ni àlááfíà wa"; èyí tumọ̀ sí pé ìwo gẹ́gẹ́ bí adé orí àlááfíà nínú ayé ọkọ rẹ n ṣojú Jésù, èyí ni pé, ọ gbọ́dọ̀ máa ṣìpẹ̀ fún un nígbà gbogbo.

Yí gbogbo omi ní àyíká rẹ (omi ìwẹ̀ tàbí omi mímu) sí ẹ̀jẹ̀ Jésù. Nípa ṣiṣe èyí, ìwọ yíò mú ọkàn rẹ̀ wá sọ́dọ̀ ara rẹ àti s'ọ́dọ̀ Olúwa wa Jésù Kristì. Èyí ni ojúlówó ìpinnu Ọlọ́run fún ìgbéyàwó rẹ, kí ẹ̀yin méjèèjì lè jẹ́ ọ̀kan.



Efésù 2:13, "ṣúgbọ́n nísinsìnyí nínú Krístì Jésù, ẹ̀yin tí ó ti jìnnà réré nígbà àtíjọ́ rí li a mú súnmọ́ tòsí, nípa ẹ̀jẹ̀ Krístì." Ọkọ rẹ̀ jíò padà sọ́dọ̀ rẹ dájúdajú nípa ti ara àti ní ti ẹ̀mí ní orúkọ Jésù. Àmín.

Wíwá Ọlọ́run láti rí I, nípa kíka ọ̀rọ̀ Rẹ̀, nípa àdúrà àti ààwẹ̀, nípa ìgbé ayé ìwà mímọ́ àti ọkàn mímọ́ jẹ́ kókó pàtàkì. Mo gbàdúrà pé Olúwa yíò ràn wá lọ́wọ́ ní orúkọ nlá Jésù. Àmin.

## ORÍ KẸTA

# ÀWỌ̀KỌ́ṢE

**Ọkùnrin kan sì mbẹ ní Máónì, ẹnití iṣẹ́ rẹ mbẹ́ ní Kárméĺì, ọkùnrin náà sì pọ̀ gidigidi, ó sì ní ẹgbẹ̀ẹ́dógún àgùntàn, àti ẹgbẹ̀rún ewúrẹ́, ó sì n rẹ́ irun àgùntàn ní Kárméĺì**. 3. **Orúkọ ọkùnrin náà sì n jẹ́ Nábálì, orúkọ aya rẹ̀ sì n jẹ́ Abígáìlì; oún sì jẹ́ olóye obìnrin, àti arẹwà ènìyàn; ṣùgbọ́n ònrorò àti oníwà búburú ni ọkùnrin, ẹni ìdílé Kalẹbù ni óun sì ṣe**." 1 Sam 25:2-3

Bíbélì ṣe àkọsílẹ̀ rẹ̀ wípé Abígáìlì jẹ́ obìnrin olóye tí ó dára. Obìnrin tí ó dára láti wò. Ó ṣe pàtàkì fún ọ gẹ́gẹ́bí obìnrin àti ìyàwó láti kẹ́kọ̀ọ́ lára ọgbọ́n Abígáìlì.



## ỌGBỌ́N ABÍGÁÍLÌ

1. Ó tètè ṣe èyí tí ó pinnu láti ṣe láti gba ìdílé rẹ̀ là (pẹ̀lú ara rẹ̀). 1Sam 25:18a, 23a.
2. Ó pinnu láti fún Dáfídì àti àwọn ọmọkùnrin rẹ̀ nínú ọ̀pọ̀ tí òun àti ọkọ rẹ̀ ní. 1Sam 25:18b
3. Kò tilẹ̀ sọ fún ọkọ rẹ̀, 1Sam 25:19c.

   Ó ṣe dandan fún ọ láti mọ̀ wípé o kò ní láti sọ àwọn nkan kọ̀ọ̀kan fún ọkọ rẹ.

   **Àkíyèsí:** Èyí kìí ṣe fún gbogbo ènìyàn; ó wà fún àwọn tí wọ́n ní ìfura ẹ̀mí ju ọkọ wọn lọ, bóya agbára ayínipo wà tí ó n ṣiṣẹ́ (darí ọkọ rẹ), bí ó bá jẹ́ pé àìsọ fún un yóò gba ẹbí rẹ là.
4. Ó jẹ́ ẹni tí ó ṣe ṣámú-ṣámú: ó pàdé Dáfídì àti àwọn ọmọkùnrin rẹ̀ ní òdé, ó sì yára lọ ípàdé wọn. 1Sam 25:20d

5. Ó jẹ́ onírẹ̀lẹ̀, ó tètè tẹ orí ba níwajú Dáfídì ní kété tí ó rìí. Ó dojúbolẹ̀, 1Sam 25:23, "Ábígáìlì sì rí Dáfídì, òún sì yára, ó sì sọ̀kalẹ̀ lórí kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́, ó sì dojúbolẹ̀ níwájú Dáfídì, ó sì tẹ ara rẹ̀ ba sílẹ̀."
6. Ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ̀: ó yára pe Dáfídì ní "Olúwa mi", 1Sam 25:24
7. Ó gbẹnu sọ fún ọkọ rẹ̀, ó dúró fún ọkọ rẹ̀. 1Sam 25:24b. "Jẹ́ kí ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ wà lórí mi."
8. Ó n bẹ̀bẹ̀. 2Sam 25:24c "mo bẹ̀ ọ́."
9. Ó sọ̀rọ̀ pẹ̀lú ọgbọ́n. 1Sam 25:28, "Olúwa mi, èmí bẹ̀ ọ́, má ka okùnrin béliálì yìí sí, àni Nábálì: nítorí pé bí orúkọ rẹ̀ ti jẹ́ bẹ́ẹ̀li òún rí: Nábálì li orúkọ rẹ̀, àìmọ̀ye sì wà pẹ̀lú rẹ̀; ṣùgbọ́n èmi ìránṣe rẹ kò rí arákùnrin olúwa mi, tí ìwọ́ rán wá." 1Sam 25:25



10. Kò díbọ́n. 1Sam 24:29-30. Àbígáìlì kìí ṣe ẹnití ó n díbọ́n, ó n sọ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyìí láti inú ọkàn rẹ̀. Irú ẹni tí òún jẹ́ ni èyí.
11. Ó gbàdúrà fún Dáfídì. 1Sam 25:29-30
12. Ó mọ inú Ọlọ́run. 1Sam 25:30

Èyí nipé, o gbọ́dọ̀ jẹ́ krístẹ́nì tòótọ́ tí ó sì fi ara rẹ̀ jì. O gbọ́dọ̀ jẹ́ krístẹ́nì tí ó n dúró de Olúwa. Ó mọ ìdarí Ọlọ́run, jẹ́ obìnrin tí ó n wá láti mọ inú Ọlọ́run. Ó mọ inú Ọlórun fún Dáfídì, ó sì sọ fún un, wípé Dáfídì yíò jẹ ọba lórí Ísráẹ́lì, àwọn èniyàn Ọlọ́run.

Dáfídì mọ rírì ọgbọ́n àti òye rẹ̀ nínú 1Sam 25:33a, "ìbùkún ni fún ọgbọ́n rẹ, alábùkún fún sì ní ìwọ."

## ÈRÈ/ÀNFÀÀNÍ JÍJẸ́ OLÓYE OBÌNRIN

- Ore/ẹ̀bùn rẹ yíò jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà nítorípé ìwọ yíò fi sílẹ̀ nínú ọgbọ́n Ọlọ́run. 1Sam 25:35a.

- O ó ma gbé ígbé ayé àláàfíà. 1Sam 25:35b.
- A ó gbọ́ ohùn rẹ. 1Sam 25:35c.
- A ò tẹ́wọ́ gbà ọ́. 1Sam 25:35d.

## TÍTỌ́JÚ ỌKỌ WA

Ṣíṣe ìtọ́jú túmọ̀ sí, kíkẹ́, fífẹ́ràn, títọ́jú, dídáàbò bò lọ́wọ́ ewu, dídààbò bò lọ́wọ́ ìparun, dídààbò bò lọ́wọ́ olè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Kí o tó pinnu láti ṣe ohunkóhun, o gbọ́dọ̀ jẹ́ ohun tí ó kò kó iyán rẹ̀ kéré. Dájúdájú, ohun ti o bá kà sí iyebíye, o ó ṣe ìtọ́jú ohun náà.

Ó ṣe pàtàkì fún wa láti mọ àwọn oríṣi ìpele ìtọ́jú ọkọ wa.

- Ítọ́jú ti ara
- Ìtòjú ti ẹ̀mí
- Ìtójú ti ìbálòpọ̀



- Ìtọ́jú ti ìṣúná
- Ìtọ́jú ti làákàyè/ìrònú.

Ọ̀pọ̀ nínú wa ti jẹ́ kí àwọn ọmọ wa kí ó bọ́ sáàrin ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú ọkọ wa. A ti fi ìfẹ́ ọkọ wa fún àwọn ọmọ wa. Ó dára, tí Ọlọ́run ò bá fún wa ní ọmọ nkọ́, ṣe a fẹ́ sọ pé ìfẹ́ wa sí ọkọ wa yíò dínkù ni? Rárá o!

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú wa, ní kété tí a bá ti bí àkọ́bí wa, a máa n dá jíjẹun pọ̀ pẹ̀lú ọkọ wa dúró. Ìjẹun pọ̀ ṣe kókó pàtàkì, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a kò kọbiara si. Òun kò ní ó n gbé ìgbéyàwó ró, ṣùgbọ́n ó n mú kí ìṣọ̀kan àti ìfẹ́ kí ó jí pépé. Ohun tí ó n jí ni gírí ni.

## ÌTỌ́JÚ TI Ẹ̀MÍ

Gbìgbà àdúrà àti ṣí ṣìpẹ̀ fun ọkọ rẹ. Ó ṣe pàtàkì, pé kí a mọ̀ wípé "ìtọ́jú tí ẹ̀mí" fún ọkọ wa kó ìdajì nínú ìwọ̀n ọgọ́rùn.

**Àkíyèsí:** Ṣe àkíyèsí pé lótìítọ́, ìtọ́jú ti ẹ̀mí ni ó n jí ìtọ́jú ti ara àti àwọn ìyókù pépé.

Mo ti rí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ níbití Ọlọ́run fi ìtọ́jú àti ṣe àṣeyọrí fún àwọn ìyàwó. Nítorí náà, ní ọ̀pọ̀ ìgbà tí o bá ti fi àmi ìfàsẹ́yìn tàbí àṣìṣe tàbí ìkùnà nínú aye okùnrin, nṣe ló yẹ kí á wo ìwọ̀n àdúrà ìyàwó irú ọkùnrin bẹ́ẹ̀. Kì í sì í ṣe àdúrà lásán, bíkòṣe àdúrà tí ó gbójú.

Ó di ìgbà tí a bá kàá sí ojúṣe wa àkọ́kọ́ láti máa gbàdúrà àti ṣìpẹ̀ fún ọkọ wa, á lè má tíì mọ bí a ti ì tọ́jú wọn nípa ti ẹ̀mí. A gbọ́dọ̀ mọ̀ wípé, a kò lè fi ohun ti ara nìkan fún ọkọ wa, kí wọ́n má baà bàjẹ́.

Ọ̀pọ̀ tilẹ̀ má n sọ wípé, "njẹ́ mo ti gbàdúrà fún ara mi tán ná?" Ṣe àkíyèsí wípé nígbàtí ó bá gbàdúrà tí o sì ṣìpẹ̀ fún un, ìgbà náà ni o tó gbàdúrà fún ara rẹ tán. Jẹ́ kí á sọ ọ̀títọ́, má tan ara rẹ̀, o sì n ráhùn nípa rẹ̀ nítorípé o kò tíì mú àdúrà àti ìṣìpẹ̀ bí ohun àkọ́ṣe rẹ.

- Pàápàá nígbàtí kò tọ́jú tàbí nífẹ̀ ẹ́ rẹ
- Bíó tilẹ̀ jẹ́ pé ní ọ̀pọ̀ ìgbà koò ka àwọn ohun pàtàkì sí



- Pàápàá nígbà tí kò bìkítà nípa àwọn ìṣúná tí ẹ̀bí nílò
- Nígbàtí ó jẹ́ ọmùtípara
- Pàápàá nígbà tí ó jẹ́ oníṣìná/alágbèrè
- Pàápàá tí ó bá jẹ́ pé ní ìhà tìrẹ, ó tílẹ̀ ti pẹ́ tí ẹ ti jọ ní ìbálòpọ̀ bíi lọ́kọláya.
- Pàápàá nígbàtí kìí ṣe ọkọ tí ó lóye bíi ọkọ ọ̀rẹ́ rẹ tàbí arábìnrin rẹ.
- Ìwọ sá gbà á nísẹ́ láti máa gbàdúrà àti láti ṣìpẹ̀ fún un. Jẹ́ kí ó jẹ́ ojúṣe rẹ àkọ́kọ́, kí o tó mọ ohun tó n ṣẹlẹ̀, ọkọ rẹ yíò sì bẹ̀rẹ̀ sí nní ṣe àwọn ohun wọ̀nnì tí o ṣàfẹ́rí, ìwó yíọ́ sì ní "àrà ọ̀tọ̀ ọkọ tí o fẹ́", Àmín.

Dẹ̀kun àti máa ráhùn, gbìyànjú èyí wò. Mú ohun tí ò n kà yìí wá sí ìṣe, dájúdájú yíò ṣiṣẹ́ fún ọ. Ó tii fiṣẹ́ fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ tí ó ti wà ní ipò tí o wà yìí rí.

Njẹ́ o mọ̀ wípé o kò tíì ní àṣeyọrí àti àlùyọ ní ìpele yìí ninu ìgbéyàwó rẹ nítorí pé o kò tíì ṣe gbogbo ohun tí o ti n gbọ́. O

kò tíì mu lọ́kùnkúndùn. Níṣe lo máa n wo ẹni tí n sọ̀rọ̀ bíi aláìkójú òṣùwọ̀n, tàbí kí o wo ọjọ́ orí rẹ̀, tàbí kí o rí àwọn ìmọ̀ràn rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohun tó rọrùn, nítorí náà, o kìí kà á sí.

Mo rọ̀ ọ́ láti tẹ̀lé èyí, kí o dán an wò, bí ó ti wù kí ó rọrùn tó. O ó sì sọ ọ̀rọ̀ ẹ̀rí ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.

**Kíyèsí:** Nígbàtí mo so wí pé kí osù tó parí, àwọn kan le sọ pé kí ló dé tí kìí ṣe ọ̀sẹ̀ kan? Mo fẹ́ kí o mọ̀ wípé, kìí ṣe dandan, ẹ jẹ́ kí á dẹ́kun àti máa tan ara wa nígbàtí a kò bá ṣe dáradára. À n fẹ́ èsì, kìí ṣe ẹ̀tàn, èyí ní ṣe pẹ̀lú bí ó ti ká ọ lára sí àtí ọ̀nà tí o fi dìí mú. Kódà ní bí o ti n ka ìwé yìí, ìwọ nìkan ló lè sọ ìwọ̀n àti bóyá o lè ṣẹ́gun, ìyá wa. Mu lọ́kùnkúndùn ju ohunkóhun lọ, ìwọ yíò sì ní ayọ̀ rẹ ní orúkọ nlá Jésù.

Ayọ̀ tí a lè ṣiṣẹ́ fún ni, o gbọ́dọ̀ ṣiṣẹ́ tìrẹ jáde! Nítorí náà jẹ́ kí ó jẹ́ "ojúṣe rẹ̀ àkọ́kọ́ fún ìtọ́jú" lati gbàdúrà kí o sì ṣìpẹ̀ fún ọkọ rẹ.



Rántí pé ọkọ Abígáílì kìí ṣe ẹni rere tàbí ọkọ tó mòye, ṣùgbọ́n Abígáílì nípa ọgbọ́n àti ìrẹ̀lẹ̀ rẹ̀, gba ọkọ rẹ̀ àti ilé rẹ̀ là lọ́ wọ́ ìparun.

## ÌTỌ́JÚ TI ÌBÁLÒPỌ̀

Pàtàkí ìtọ́jú ọkọ rẹ nípa ti ìbálòpọ̀ pín sí ọ̀nà méjì; o le gbàdúrà pé kí Ọlọ́run fún ọ ní okun láti tẹ́ ẹ lọ́rùn tàbí kí o gbàdúrà pé kí Ọlọ́run dín àfẹ́rí rẹ fún ìbálòpọ̀ kù. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìdílé ni ó wà nínú ìrora, nítorí pé kò sí ìtọ́jú ti ìbálòpọ̀ tàbí àìní òye nípa àti tọ́jú ọkọ pẹ̀lú ìbálòpọ̀. Njẹ́ o mọ̀ wípé àwọn obìnrin kan a máa bí ọkọ wọ́n léèrè pé "oúnjẹ ni bí?", ọkùnrin náà a sì tètè dáhún wípé "kódà, ó ju oúnjẹ lọ."

Bí ó bá sì ṣẹlẹ̀ pé o ní òùnfà fún ìbálòpọ̀ ju ọkọ rẹ lọ, ohun kan náà ni ó n ṣẹlẹ̀. Nìtorí náà, ó tó àkókò láti mú u lọ́ kùnkúndùn. Kíyèsí pé ó tún jẹ́ ànfàní fún ọ nítorí pé o lè lo èyí bí kókó àdúrà láti ṣe àtúndá ẹ̀dá rẹ̀.

## ÌTỌ́JÚ TI ARA

A kọ́ gbọdọ̀ jẹ́ kí wọ́n lérò pé wọn ò ṣe tó. Tí o bá jẹ́ kí wọ́n dàbí ẹni tí kò kún ojú òsùwọ̀n, o ó sọ wọ́n di ọkọ tí ó n ráhùn nígbàgbogbo, tàbí kí wọ́n máa kanra, wọ́ n sì lè ma wo ara wọn bí ẹni tí ó kéré sí okùnrin ẹgbẹ́ wọn.

Njẹ́ o mọ ìdí tí mo fi n sọ èyí? Àwọn kan le máa sọ pé, ènìyàn kò lè ní irú ìdílé aláyọ̀ tí ó ṣàfẹ́rí, láì jẹ́ olówó tàbí ọlọ́rọ̀. Rárá o. Bí o kò bá lè gbé pẹ̀lú rẹ̀ báyìí, mọ̀ wípé o kò ní lè gbé pẹ̀lú rẹ̀ nígbàtí ètò ìṣúná yín bá dára sìí.

Rírà nnkan fún wọn àti pípàárọ̀ aṣọ wọn: ojúṣe wa ni èyí, ọ̀pọ̀lọpọ̀ wa ni a ó ti pàrọ̀ aṣọ wa bí ìgbà mẹ́ta sì mẹ́rin, kí a tó ránti láti pàárọ̀ àṣọ àwọn ọkọ wa lẹ́ẹ̀kan. Mo mọ̀ wípé àwa obìnrin fẹ́ràn àṣọ àti bàtà púpọ̀, ṣùgbọ́n a kò gbọdọ̀ gbàgbé ọkọ wa dé ibi ti àwọn ènìyàn kò ní le ṣe àfiwé àwa àti ọkọ wa nítorí ìyàtọ̀ nínú ìmúra.



## ÌTỌ́JÚ TI ÌṢÚNÁ

Ojùṣe wa ni láti jọ̀wọ́ gbogbo ìṣúná wa fún ọkọ wa. A ní láti mọ̀ pé, gbogbo ohun tí a ní, tiwọn ni. Ìyá wa, njẹ́ o mọ̀ wípé Olúwa n bùkún fún iṣẹ́ ọwọ́ rẹ nítorí ọkọ rẹ? Fún un ní gbogbo rẹ̀, má ṣe siyèméjì wípé yíò já ọ kulẹ̀. Kò lè ṣe é. Àbí ìgbágbọ̀ rẹ n yọ èyí kúrò ni? Ẹnikẹ́ni kò lè fọwọ́ kan ọkọ rẹ. Dá ara rẹ lójú nínú Olúwa kí o sì jọ̀wọ́ ohun gbogbo fún un.

Nígbàtí okùnrin (ọkọ rẹ) bá ti mọ̀ wípé ìwọ kò ní owó rẹ fún ara rẹ, nígbàti ó bá mọ̀ pé o ti fi gbogbo rẹ̀ fún òun, òun náà yóò fi gbogbo tirẹ̀ sílẹ̀ fún ọ. Kò wá ní fi owó rẹ̀ nìkan sílẹ̀, yíò fi ìfẹ́ rẹ̀ fún ọ pàápàá ní kíkún.

Mọ̀ wípé, bí o kò bá ní tan ara rẹ, ìwọ àti èmí mọ̀ wípé bí a bá gbà ọ́ láyè láti mú ohun kan nínú àwọn nkan wọ̀nyí, o ó gbà láti pé kí ó fún ọ ní ìfẹ́ rẹ̀ ju owó lọ. Àwọn kan lè máa ro báyìí pe, "rárá o, owó ni o, owó ni ó ṣe kókó." Bẹ́ẹ̀ni, mo mọ̀ bẹ́ẹ̀, sùgbọ́n nínú ọkàn rẹ, níbití ó jẹ́ pé Ọlọ́run nìkan ló mọ̀, ó mọ̀ wípé ifẹ́ àti

ìtọ́jú ni o fẹ́ ju owó lọ. Bí ó bá wá jẹ́ bẹ́ẹ̀, kọ́kọ́ fún un ní gbogbo tìrẹ ná, nígbàtí ìwọ́ bá ṣe èyí, nígbà náà ni o fi àmì ìtọ́jú hàn fún un.

### ÌTỌ́JÚ TI LÀÁKÀYÈ/ÌRÒNÚ

Jí ìrònú ọkàn rẹ dìdé nípa àwọn ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ. Fi ọjọ́ ọ̀la tí ó dára dáa lójú nígbàgbogbo. Àwon orúkọ tí ò n pè é máa n ṣe pàtàkì, bí àpẹẹrẹ, Olùfẹ́ ọkàn mi, Oyin, Tèmi, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Máa dúpẹ́ lọ́wọ́ rẹ̀ nígbàgbogbo, "ẹ ṣeun sà". Sọ fún àwọn ọmọ rẹ nipa rẹ̀, bí àpẹẹrẹ, "mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run fún ọkọ mi," "ẹ ṣe oríire láti ní ọkọ mi gẹ́gẹ́bí bàbá yín," "ẹ má yọ ọkọ mi lẹ́nu o," njẹ́ bàbá yín kọ́ ni bàbá tó dára jùlọ?"

Máa dá àpárá, fi ààyè sílẹ̀ fún eré síṣe. Máṣe jẹ́ ẹnití ó n lejù jù. Bí àpẹẹre, "ìgbà méjì la ma ṣe lálẹ́ yìí," àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Fi yangan. Mo gbàdúrà wípé Olúwa yíò máa bá ọ sọ̀rọ̀ ní orúkọ nla Jésù. Àmín.



## ORÍ KẸRIN

# ÀKÓTÁN

Ní ìparí, o gbọ́dọ̀ ṣèwádìí, mọ̀, kí o sì ṣiṣẹ́ lórí ìfẹ́ Ọlọ́run fún àwọn ọmọ rẹ. Njẹ́ o mọ̀ wípé, àṣeyọrí àwọn ọmọ rẹ náà n fi bí ìgbéyàwó rẹ ṣe rí hàn? Ọkan nínú àwọn òṣùwọ̀n àṣeyọrí ìgbéyàwó rẹ ló jẹ́.

Ẹ jẹ́ kí a wo "Màríà," ìyá Jésù. Ó mọ ètò Ọlọ́run fún ọmọ rẹ̀; ó mọ èròngbà Ọlọ́run fún Jésù. Ó mọ agbára tí Ìmmanúẹ́lì ọmọ rẹ̀ gbérù tí ó sì ní. Nínú Jòhánù 2:3, Bíbélì sọ wípé, "Nígbàtí wáìnì sì tán, ìyá Jésù wí fún un pé, wọn kò ní wáìnì."

Ó mọ̀ wípé Jésù ní agbára láti ṣe iṣẹ́ ìyanu. Ó ṣe pàtàkì fún ọ, gbẹ́gẹ́bí ìyá, o ní láti mọ ìfẹ́ àti ìpinnu Ọlọ́run fún ayé àwọn ọmọ rẹ. Mò n sọ nípa ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn.

Bíbélì sọ wípé, ọmọ ni ìní àti èrè Ọlọ́run. Ó yẹ kí o mọ̀ pé, a kàn fi ọ́ ṣe

olùtọ́jú ìkọ̀ọ̀kàn àwọn ẹ̀bùn iyebíye tí Ọlọ́run fi fún ẹbí rẹ ni. Nítorí náà, ó ṣe pàtàkì láti mú wọn wà ní ìgbáradì ní ọnà tí Ọlọ́run Ẹlẹ́dàá wọn yíò fi tẹ́wọ́ gbà wọ́n láti lò fún ògo rẹ̀ nínú ayé wọn. Ojúṣe rẹ ni bí òbí, bóyá o lówó tàbí o kò ní, o kàwé tàbí o kò kà, oníṣẹ́ ìjọba tàbí olókoòwò, olùsọ́àgùntàn tàbí ọmọ ìjọ, láti kọ́ àwọn ẹ̀bùn pàtàkì tí ó ṣe iyebíye tí Ọlọ́run ti fún ọ (àwọn ọmọ rẹ) ní ọ̀nà Olúwa. Rántí pé Bíbélì sọ pé "tóóró ni ọ̀nà sí ọ̀run."

Nítorínáà, o ní láti mọ̀ pé ọ̀nà tí Ẹ̀mí Mímó yíò ma darí àti ràn ọ́ lọ́wọ́ láti tọ́ àwọn ọmọ rẹ le yàtọ̀ sí ọ̀nà ti ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn mìírà. Èyí jẹ́ bẹ́ẹ̀ nítorí àwọn tí ó n rin ọ̀nà àgbélébù kò pọ̀ rárá. Bí o kò bá sí nínú àwọn ẹni tí n rìn tí ó sì n tọ́ àwọn ọmọ wọn ní ọ̀nà Olúwa, jọ̀wọ́, àkókò ti tó fún ọ láti gba ojúṣe tí ó ṣe gbógì jùlọ láti tọ́ àwọn ọmọ rẹ ní ọ̀nà tí wọn yíò tọ̀.



Bíbélì wípé, nígbà tí ó bá dàgbà tán, kì yíò kúrò nínú rẹ̀. Jẹ́ ọlọgbọ́n ìyá wa, má ṣe fi ọjọ́ ìgbàlà tìrẹ àti àwọn ọmọ rẹ dọ́la. Oní ni, àkókò yìí sì ni pẹ̀lú.

Ṣe àkíyèsí pẹ̀lú, Màríà sọ fún àwọn ọmọ èyìn Jésù nínú Jòhánù 2:5b, "Ohunkóhun tí ó bá wí fun yín, ẹ ṣeé.," nítorí ó mọ̀ dájú ohun tí ó n bẹ nínú ọmọ rẹ̀. Kì í ṣe ìyá tí kò kíyèsára; ó fura sí èdè ti Ẹ̀mí Mímọ́. Ó wà ní ìmúrasílẹ̀, ó sì ní òye àyíká rẹ̀.

Bákannáà, ni Olúwa, Olùfúnni ní gbogbo ẹ̀bùn dídára, Òun tí ó fún ọ ní àwọn ọmọ rẹ yebíye, fẹ́ kí o jẹ́. Kí o ní àwon àmúyẹ Màríà kí o ba lè ní ayọ̀ nínú ìgbéyàwó àti ìdílé rẹ.

Mo gbàdúrà pé Olúwa Jésù Krístì yíò fún ọ ní ore-ọ̀fẹ́ lóníí. Àmín.

Báwo ni o ó ṣe mọ ìfẹ́ Ọlọ́run fún àwon ọmọ rẹ?

1. Ó jẹ́ dandan, tí o bá fẹ́ mọ ìfẹ́ Ọlọrun fún ọmọ rẹ, o ní láti kọ́kọ́ mọ ìfẹ́ Ọlọ́run fún ayé tìrẹ. O lè sọpé "Ní ọjọ orí wo?" Rárá o! Ọjọ́ orí rẹ lọ́wọ́lọ́wọ́ kìí ṣe ìdíwọ́, Ọlọ́run wa, Àìkú àti Àìṣá ni. O sì le tọ̀ Ọ́ lọ, Ó wà níbẹ̀ fún ọ. Rẹ ara rẹ sílẹ̀ níwájú Rẹ̀, Òun yíò fi ara Rẹ̀ àti ifẹ́ Rẹ̀ fún ayé rẹ hàn ọ́. O kàn ní látí gbé ìgbé ayé òdodo, kí o sì jẹ́ onírẹ̀lẹ̀ níwájú Rẹ̀.

   Sì kíyèsí, o kò lè fún ni ní ohun tí ìwọ kò ní. O kò lè wá kiri, kí o sì mọ ìfẹ́ Ọlọ́run fún ọmọ rẹ bí o kò bá tíì mọ ìfẹ́ Ọlọ́run fún ayé tìrẹ. Mo gbàdúrà wípé ore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run yíò tó fún ọ ní orúkọ nlá Jésù, Àmín.

2. Ṣe àwọn ọmọ rẹ bí ìní Ọlọ́run. Bá wọn ṣe ní ọ̀nà tí Ọlọ́run yíò fi ni wọ́ n bí èrè nlá. Má ṣe jẹ́ kí ọ̀rọ̀ wọn mu ọ́ lómi púpọ̀ jù. Jẹ́ kí Ọlọ́run ó ni ààyè lórí wọn. Mo gbàdúrà wípé ore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run yíò tó fún ọ ní orúkọ nlá Jésù, Àmín.



3. Jẹ́ onírẹ̀lẹ̀ tó láti gba ìfẹ́ Ọlọ́run fún wọn. Bí o bá tọ́ wọn ní ọ̀nà ti Olúwa, Olúwa ò ní ṣàì yan ipa ọ̀nà sí àṣeyọrí fún wọn, wọn kì yíò sì ṣíṣe ní orúkọ nlá Jésù, Àmín. Ó ṣe pàtàkì fún wa látí mọ̀ wípé, bí a bá ti tọ́ àwọn ọmọ wa ní ọ̀nà ti Olúwa, àtí pẹ̀lú gbogbo kókó ọ̀rọ̀ tí a ti sọ ṣáájú, àwa yíò ní ìdílé aláyọ̀ tí ó mọ Ọlọ́run tí a fẹ́.

   Mo gbàdúrà wípé, kí Olúwa kí ó ràn wá lọ́wọ́ bí a ti n pinnú láti tẹ̀lé gbogbo ohun tí Olúwa ti kìlọ̀ fún wa nínú ìwé yìí nípa ore-ọ̀fẹ́ Rẹ̀ ní orúkọ nlá Jésù, Àmín.

   Jẹ́ kí n rán ọ létí pé, mo ti kọ àkọsílẹ̀ kékeré yìí pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ Ẹ̀mí Mímọ́, ẹni tí èmi n tọ́ka sí fún ọ bí alábàárìn tòótọ́. Ìpinnu mi ni kíkọ́ rẹ̀ ni láti ṣe ọ́ gírí àti láti fi dá ọ lójú wípé ohun tí ò n rí bí ìrírí wà lára ore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run fún ọ. Dúró ṣinṣin nínú ore-ọ̀fẹ́ yìí.